Ọrọ agba

OPERÉKÉTÉ ndagba, inu adamọ mbaje. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

Irohin Yoruba

Akiyesi

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona.

NO. 106 WEDNESDAY APRIL 15 —TUESDAY APRIL 21 1964 KOBO MẸTA 3D

AWỌ BẸRẸ ẸJỌ AJABỌ

Ogbẹni Victor Durand ti ise ogbonkangi ati olokiki agbejoro fun Obabinrin ilẹ Geesi ti o ngbenuso fun Oloye Obafemi Awolowo, babasalẹ egbẹ Afẹnifere Naijiria ninu ejọ kotẹmilorun ti o pe lori idajọ ewọn odun mẹwa ti ile-ejọ giga kan da fun ni osu kẹsan odun ti o kọja lori esun lati doju ijoba delẹ se gbaagbe ati iye lori idajọ na ni ile ejọ ti o ga julọ l'Eko ni ọjọ kẹwa osu yi.

OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Awẹ gbigba fun Awo

EKA egbẹ Omọ Oduduwa Ila Orun kesi awọn omọ yoruba jakejado Naijiria pe, ki nwọn gba awẹ ọjọ mẹta fun Oloye Awolowo.

Nwọn se ipinnu yi ninu ipade kan ti nwọn se ni Aba ni ọjọ Aiku ti ise ọjọ karun osu kẹrin odun yi pe, ki nwọn gba awẹ mẹta fun Oloye Awolowo pe ki Oluwa le fun ni okun agbara ati isegun lati le fi bori ninu ejọ kotẹmilorun ti o nse lọwọlọwọ yi, ti o bẹrẹ ni ọjọ Eti ti ke ọjọ kẹwa osu kẹrin odun yi.

Nwọn tun tako Ijoba Ipinlẹ Iwọ Orun fun ọna idilọwọ ere Ogunde ni Ipinlẹ na, nwọn ni, ase na lodi si ilana ati ofin ki eda se ohun ti o fẹ lairekoja ofin. Egbẹ na ni o to asiko gọọ, "ki awọn omọ yoruba ronu wo lori iwa aghajelenu enia ti Ijoba NNDP hu yi paapa julọ ni ile abinibi wa".

Ninu ọrọ ti alaga egbẹ na Ogbẹni Musibau Odebiyi ba awọn oniwe irohin sọ, o ni "egbẹ mi wa lẹnu eto sise, lori pe "Ogunde Concert Party" wa se ere akonilogbon rẹ "Yoruba Ronu" ni Ipinlẹ Ila Orun.

Egbẹ Ọjọ Omọ Ogun Awolowo paapa fun kesi gbogbo awon omo egbẹ Afẹnifere jakejado Naijiria pe ki nwon gba awẹ ki nwoa si kun fun adura kikun niwu ọsẹ ti o koja yi.

Ninu ikede kan ti o jade ni Ibadan ni ojo Aje ti ise ojo kefa osu kerin odun yi ni egbẹ Odọ na ti damoran na ninu ipade kan ti nwon se.

Egbẹ na tun kede pe, ki gbogbo awon omo egbẹ na kun fun adura kikun pe ki Oluwa le se amona awon ti yio joko lori aga lẹjọ ni ojo na nipa oro ejo kotẹmilorun ti Oloye Awolowo pe.

Ogbẹni Durand se alaye fun awọn adajo marun ti nwon ngbọ ejọ na bayi. "Abuku nlanla ni yio je fun eto idajọ orilẹ ede yi bi a ko ba se ayẹwo idajo ti ile ejo giga na da".

Ninu ore akoso rẹ, agbejoro na so pe, ko si ohun ajeji ninu idi ti nwon fi ju ẹ l ẹ j o on si ọgba ẹwon nitoripe o le selẹ si ẹnikẹni.

Nigbati o gbe hab nla alaye kalẹ lori idajo ti odun ti o koja ninu eyi ti nwon ti so pe Oloye Awolowo banujẹ lẹhin ti egbẹ re ti kuna ninu idibo si Igbimo Asofin Apapo ni odun 1959, o so pe ki ise ara oto fun enikẹni ti o ba kuna ninu idibo lati banuje. Pelu erin, o so pe iru ibanuje be ko ni sai sẹle si okan ninu awon asiwaju egbe oselu ti o wa ni Ilẹ Geesi laipe yi lehin ti nwon ba di ibo tan.

Lori eri awon eleri ti o jeri fun Ijoba, o so pe o se ni lanu pe idajo ile ejo giga ti o da ejo na faramo eri ti Dokita Onabamiro ti ise Alakoso eto ogbin Ijoba Ipinle Iwo-Orun nisis yi je nigbati je nigbati o ko eri ti Dr Aluko je.

Ogbẹni Durand so fun awon adajo na pe ninu oro ajabo on fun Oloye Awolowo on ylo wo eri Onabamiro mole tutu lori ohun ti o pe ni Igbimo Awo ve lori eyiti adajo gbe pamo re ka.

Lori iwe kan ti nwon npe ni Twelve Portraits of Power" ti ise ilana mejil "un agbara eyiti nwon ti ro ejo mọ elejo on, Ogbẹni Durand so pe awon akeko ti o fe se idanwo eko giga "General Certificate of Education" ni nwon se iwe na fun ni pataki julo, nitorina ki ise ohun ajeji fun enikẹni lati ka.

Awon adajo agba marun ti ngbo ejọ na ni: Olola Adetokunbo Ademola, Olola Louis Nbanefo, Olola Lionel Brett

(Wo oju ewe kẹjọ)

IJẸWỌ IGBAGBỌ AFẸNIFẸRE:

Mo gba eto iselu Afẹnifẹre gbọ.
Mo gba Awolowọ gbọ pẹlu.
Eniti o da egbẹ Afẹnifẹre silẹ
Awo ti o je aromọdomọ Oduduwa
Eniti a fi eje iselu bi
Eniti a bi ninu Maria Efunyẹla
Eniti o jiya nitori awa mẹkunnu
Eniti a gbe sinu tuba
O fọkan balẹ s'ogba ẹwọn
Lati ma seto silẹ fun Ijoba idẹra
Nibiti yio ti pada wa se Olotu Ijoba Naijiria.
Mo gba ilana nipa idẹra fun gbogbo enia gbọ.
Mo gba Egbẹ Omọ Oduduwa gbọ
Agbega s'oke owo koko
Irọrun fun awọn agbẹ
Ifọkanbalẹ fun awọn osise
Ati idaghasoke ti ko nipẹkun.

J. A. F. OGUNLAYI, IKOLE

Aworan oke yi fi bi awon olopa se 'ntoju' awon janduku han.

'Ijọba' janduku gbode kan

OJỌ kefa osu yi je ojọ esu gbomi mu fun gbogbo awọn janduku egbẹ oselu ni ilu Ibadan bi awọn olopa ti nti kọrọ kan de ikeji lati ko gbogbo wọn.

Bi awọn janduku egbẹ NNDP ti ri ogunlọgọ Olopa ti nwọn nbọ wa ko wọn ni ibiti awọn ọga wọn fi nwọn ha si ni Iyaganku ati Agodi Ibadan ni nwọn ba fẹsẹ fẹẹ, ti opọlọpọ si sa wọ igbo lọ sugbọn owọ olopa tẹ wọn. Bakanna ni owọ tẹ awọn janduku egbẹ oselu miran.

O ju ogorun awọn enia bẹ ti awọn olopa ko lọ si ọja wọn ti Iyakanku. Bakanna ni owọ tẹ awọn ọkọ wọn.

Eyi ni o tẹle iwa jagidijagan, adaluru ati gunbegunbẹ ti awọn janduku egbẹ NNDP nbu kakiri. Ipinlẹ Iwọ Orun ni kete ti nwọn da egbẹ na silẹ, ti nwọn si ri won pe awọn enia Ipinlẹ yi ko gba ti egbẹ na.

OSHOGBO: Onirohin wa se akiyesi si pe awọn janduku egbẹ NNDP lo da ilu Oshogbo ru ni ọjọ ketadinlogbọn osu kẹta odun yi ti nwọn si bi ogunlogo dukia je ni ilu na.

OGBOMOSHỌ: Egbẹ odọ "Okpara Youth Brigade fi esun kan ni Ibadan ni ọjọ keje osu yi pe awọn janduku egbẹ oselu kan dana sun ile alaga wọn, Ogbẹni Sunmonu Akintunde. Egbẹ na si fi esun kan ogunlogo awọn omọ egbẹ won is awọn janduku na palara. Ara awọn ti o wa ni Ile Iwesan ni Ogbomọshọ ni B llo Akanji, Samuel Alawo A. Jacob ati Thomas Adeleke.

ILESHA: Ni ọjọ kẹrin osu yi ni awọn janduku egbẹ NNDP da rogbodiyan nlanla silẹ ninu eyiti ogunlọgọ dukia iyebiye segbe, ti opọ enia si fara pa. Awọn janduku egbẹ NNDP wa ninu ile ejọ bayi.

AKURẸ: Ni ọjọ kẹrin osu kẹrin odun yi bakanna ni awọn janduku egbẹ NNDP ta jamba orisirisi fun awọn ọmọ ile-iwe ati awọn obinrin ti o nta ọja ni ilu Akurẹ. Opọlọpọ awọn nkan ti nwọn nta lọja ni awọn janduku na ji.

Ejọ esun ole ti nwọn fi kan mejọ ninu nwọn wa ni ile-ejọ bayi.

Nitori gbogbo iwa gunbegunbẹ egbẹ NNDP, o to ọdẹgbẹta awọn olopa ti o ndekun rogbodiyan ni nwọn ti ko wa si ilu Ibadan bayi lati koju alafia ati ofin ti egbe NNDP fe ja tile ni Ipinle Iwọ Orun Naijiria.

Gbogbo igba ni awọn olopa ma nfi agbara won han nipa ri rin kakiri ilu Ibadan ninu oko won.

Gbadun Ẹmi ẹ pẹlu STAR

Ọti Beer toghamuse!

Ọrọ Olotu

Aṣiwaju Apapandodo

YORUBA ni "Eniti a ko fẹ ni awuje ti o ni on yio da ese; bi o ba da ese na ti ko ri emie gbe ako?" Eyi gan ni ima ti Oloye Akintọla ran lori ero gbohungbohun laipe yi. Abuku ọda ni pe ko le si ara re gege bi araiye ye ni. Bi ki iba se be ni, Oloye Akintọla iba mọ pe ọna ea arun bayi lati se pe iyokan Yoruba ni on nfe ni wakati kokoala aje. Ki ise igbati emia ba le pariwo bi owuro lori ero gbohungbohun ni araiye ta le mọ ohun ti o njijide fun. Ise atukuluku ni yio se idaje.

Ki iba se wipe Oloye Akintọla fẹ ki araiye gba pe Oloye Awolowo le se awọn emọ Yoruba sinu iponju ati ipo ebo, ati pe on (Akintọla) ni o nja fun eto wọn? IROHIN YORUBA ro wipe ko dara fun gbogbo wa lati se atepe lati se pe on Ajiinsawo.

EYI yi gan ni a fi so wipe emu Oloye Akintọla arun. Ko le je ọdaran ki o tun je adaje ni akoko kan na. A ro wipe awọn adibo ni iba jẹki o dajo awọn ero yankanyankan ti o ti ipase re yo si awọn emọ Yoruba yi. Oloye Akintọla gbodo mọ aipe awọn ti on mba ero lori ero gbohungbohun ki ise alaimọkan.

ṢAKI aye bi ora, opolopo aye bi ora. Atamọtamọ ti gbogbo aye gbo leru awọn afibinolore nibi igbimọ Iwadi Coker ni Oloye Akintọla tun tẹnumọ wipe ero egbe oniṣowo NIPC. A ti gbe aria yi lokan. Taki Oloye Akintọla ko ri orin miran ko mo ni? Ohun ti o nilati tẹle akajade iru igbimọ iwadi bẹ ni idibo yagbọn Oloye Akintọla ko idibo aiteripe araiye ti ri idi adie. Tani ko mọ bi a gbe gbi fun alare, bi a ti gbe ara fun ele? Gbogbo wọnyi ni awọn omọ Yoruba ti.

IBERE wa nipe owo ti ijoba ya egbe oniṣowo kan ha to lati fa iponju ti ka ni ati ba awọn enia lọkan na? Bi ijoba se ya NIPC lowo ni awọn ti ya ogunlogo egbe oniṣowo miran lowo. Ijoba Akintọla paapo ya egbe oniṣowo NIPC lowo. Taki o lọna nigbana ni? Oloye Akintọla ka ha iwe omọluabi lati se pe egbe NIPC ji owo awọn araawo-ori. Bi o ba je wipe aiteripe ni egbe NIPC ji owo awọn araawo ori, ile ejo ko lati dajo ole ni? Bawo ni ole se le ji owo, ki o tun maa san ele le owo na lori? Lohin ti egbe NIPC ti san owo na pada, kini Ijoba Akintọla fi owo awọn araawo ori na se? Ki Oloye Akintọla wa orin miran ko aiteripe orin ti enia ba fi odidi odun meji ko, ti ko si ri enia ba ko; o ye ki o rona.

ỌSUN miran ti o tun fi kan Oloye Awolowo nipe o ko lati je akobata fun awon ọlẹgbẹ re ni Oke Ora ati Ipinle Ila Oran. A gbodo so fun Oloye Akintọla pe awon omọ Yoruba ko le gba lati je akobata fun eya miran. Boya Oloye Akintọla ko mọ idi ti re awon omo Yoruba fi gba ti Oloye Awolowo, ti nwon si fi ko ti on. Awon omọ Yoruba gbagbo pe Oloye Awolowo ko le ko won lo si oke ora. O se eyinbo loju. Eno wa nipe ki o maṣe wo awọn enia alawọ dudu bi tire loju? Enikeni ti o ba je ije re da oju ami yie duro niwaju awọn oba, ki ise niwaju awọn enia lasan. Owọ Awolowo mọ. Owọ eniti ko ba mọ ni ki o yora lati je ọna kanbaye.

ARA awọn ọna ti Oloye Akintọla fi kan Oloye Awolowo ni wọnyi. Ibere wa nipe awọn ọna wọnyi ha to lati gbe awọn omọ Yoruba sinu egbun iponju alailopin ati ifasẹhin alaala labe ijoba Akintọla? Awolowọ ha ni Olotu ijoba bayi tabi Akintọla? Awọn omọ Yoruba ti wi nipa Awolowọ pe o se iwọn ti o le je yagbọn Akintọla nko? Bi Oba ti o te ilu do se je konigbagbe ni oba ti ilu di ahoro mọ lori yio se je konigbagbe.

OMI ti a ba da si ara eyin adie ki imọ lara. Ko si iro kan ti enikeni le ra ba Awolowọ nitoriyi mọ. Awọn omọ Yoruba ti te ile obe meji wo. IROHIN YORUBA ro wipe ki ise iwa omọluabi fun Oloye Akintọla lati taka Oloye Awolowo nigbati o ro wipe ko wa ni ipo lati daabo. Ebun lo ku ti a nfi omọ ha a we. Oloye Akintọla kere si obun ti o se yen bi o ba je wipe Oloye Awolowo wa ni ipo lati dabun. O koja Sardauna ti o je oga awon oyelu kan ni Ipinle Iwọ Oorun lati pe ọna kanbaye si Awolowo.

TANI enikeni o fa awon omo Yoruba sinu aisokan? A ti se alaye, Awon oyelu ti awon ro wipe awon le jija a gi wa je won lese lati joba ni. Awon ni oyelu ti o ko awon omo iya won sinu iya ati iponju niteori owo ati ipo. Awon ni o mọoko lasi imọ awon afobaje. Ki o ro ki lakan won—awon apanimaseyede.

OLORUN ni o nfi enia si ipo aṣiwaju, ki ise enia fun ara re. Olorun ti fi Oloye Awolowo se aṣiwaju awon omo Yoruba. Opa ko le pa agogo, ab ọn gbi ko le pa badara da. Omọ araiye le yi atite lorun ṣugbọn awọn ko le pa otito. O se, ko si aye mọ fun ọdalẹkọdalẹ lati wa se aṣiwaju apapandodo fun awọn omọ Yoruba!

Alapara Ibadan

Alapara: E ku owuro o Olutu, Se alafia ni e ji o?

Olotu: Alafia ni mo ji o. Kini kan ko si lara mi o.

Alapara: Mo so fun nyin ni ọsẹ ti o koja pe mo ti bẹ irin ajo mi de Ikeja ati agbegbe re, niniyi. Agege ni mo fi se ibujoko, lati ibẹ ni ngo si ti maa ṣẹṣẹ kọọkan de awọ ilu pẹpẹ pẹ ti o wa ni agegbe ibẹ.

ALAPARA IBADAN

Olotu: Emi ati awọn onkawe mi paapa ti nduro de o ni ọsẹ ọsẹ lati ma a gbo ohun ti o nsele nibe.

Alapara: Ohun kini ti oju mi kọkọ ri to ei ile hihaya.

Olotu: Ewo ni ti oju riri to nipa ile hihaya? Sebi o ni owo lowọ lati fi haya ile.

Alapara: Bẹẹ ko Olotu, nitoto ni owo wa lo yo mi lati fi haya ile, sugbọn awọn onile Agege ko lati fi ile haya fun mi ni o.

Olotu: Kini fa ti o fi ri bẹẹ?

Alapara: Ọrọ egbe ọse la ko se egbe oselu ti mo fe haya ile lọwọ re, o ni ti egbe oselu wo ni mo ese

Olotu: Kini o fi dalohun?

Alapara: Mo mọọmọ ni egbe "Demọ" ni mo ese nitoripe mo ro pe, ti egbe akotileta na ni nwon faramo ni Agege,

Olotu: Esi wo ni o da pada fun le?

Alapara: Oro iu redio ni o fi da esi pada fun mi, O ni "Awa ko fe mọ omo egbe Akotileta nihin, lo se ile keji," mo wo su u, ni mo ba tun rekoja si ile keji. Bakanna ni onile keji tun wi fun mi. Mo moomo de bi ile mejo nse ni nwon nle mi bi eni le aja pe nwon ko le fi ile haya fun mi nitoripe omọ egbe akotileta ni emi nse atipe awon ko le je ki nko ti ile awon ta.

Olotu: Bee lo yi ilu ka, ti o ko fi ri ile haya Alapara?

Alapara: Mo ri ile haya nikẹhin Olotu nigbati mo fi ara mi han onile kosan pe omo egbe Olọpe hanun hanun ni emi se.

Olotu: Ase awon egbe akotileta wonyi titẹ kakiri ilu bayi?

Alapara: Nwon ti tẹ nwon ko dun obe kakiri Naijiria Odua ti sọ won deni atanu, ori alaise Oloye Awolowo ti nwon ko ba lo ti nwon kakiri gbọngbọn, on na ni yio si ti won ja Olotu. Ni kukuru egbe NNDP omo Yoruba ati Omo Onifi ti fori sanpọn ni Naijiria.

ALAPARA PADE KANSELO B

Alapara: Olotu, e jeki nsọ diẹ ninu oro ajumosowopo emi ati kansele AG atijo kan ti o nfi bojuboju se NNDP.

Olotu: Se ohun ti o wi Alapara

Alapara: Ohun ti a jiyo so ni eyi Olotu Kanselo na sọro, o ferẹ te ile la.

Olotu: Mo mọ pe, o njlati ri oro gan an ni o.

Alapara: Awọn oro ti mo bere lọwọ re ni yi o. Kanselo "B" kini gbe o de inu egbe awon odale yi tabi o ko mo pe. Ogbeni "AKATANLA" ti o jiṣe Oloye Awolowo pelu Alagbara ni furo ti o jin Okpra lẹsẹ si nwon da egbe NNDP sile ni?

Kanselo B: Mo mo dajudaju pe, awon obaiyeje omo Yoruba bi awon ti e daruko yen na ni o da sile nitoto ki ngto se oju aiye wo egbe won na, ko si nkan meji ti o mu wọ egbe na ju akowa la ati adawala wan. Alapara: Humo akowaba ati apawala lati odo awon egbe na.

Kanselo 'B' Iwọnba ọrọ ni a nọ fun ọmọluabi ti o ba de

(Wo oju ewe karin)

YORUBA, RONU!

O ṣeni lanu wipe awọn oselu ti nwọn njoba laidibo ni Ipinle Iwọ Oorun loni ko ni eje enia gidi lara, nwon ko ni gbe onje lọna alaiṣẹ. A ha le wipe ijoba ti o gba onje lọna Hubert Ogunde ati awon elere re laifi omiran repo re ngbero lati joba pe? Iru ijoba bẹ ko ni ireti ore ofe alajobi.

A ti se tẹle pe Yoruba ni ota Yoruba paapa julọ awọn Yoruba ti o nse ijoba loni. Hubert Ogunde se ere re nigbati awọn olawo funfun ti nse akoso ijoba ni Naijiria, nwon ko gba onje lọna re. O di ogun ọdun ti Hubert Ogunde ti nse ere re ki ijoba Akintola to gba onje lọna re. Laise ani-ani, ko si elere ibilẹ ti okiki re tayọ ti Ogunde laria awon omo Yoruba. Ogunde ko mọ ipe miran lẹhin ere yi. Ebun ti Olorun fun niyen. Ijoba Akintola de gbun na lore, o da awọn emọ Yoruba lara!

IJOBA yi kanna le yo Alhaji S. O. Gbadamosi, Oloye F. R. A. Williams ati Oba Samuel Akinsanya kuro ninu ile Igbimọ Labọba. Nwọn ry Oba Haji Adebọwale ti Isẹyin loye; nwọn gba oye Kọla Balogun; nwon yo Ojogbon Victor Oyenuga ati awon elẹgbẹ re kuro lọna ipe won. Lohin ti egbe Akintola NNDP ti o ase ijoba loni laidibo da ragbodiyan silẹ ni Ilẹsha tan, awon tan fe yo ọna ile iwe na, Alufa J.A.Akinyemi ti ko mọwọ-mọse lọna ipe. Nwọn si le awon akọko ile iwe na sita.

AWỌN omo Yoruba ni akan wonyi ṣẹlẹ si. Bi ijoba yi nkigbe pe ijoken awọn omọ Yoruba ni awọn nfe. A ko gbagbọ pe ijoba ipa ni o le fa ipoken awọn enia ni ibikibi. A ro wipe iwa ipa ni ijoba Akintola ko lati gba onje lọna Ogunde ati awọn elere re. A kesi gbogbo awon omo Yoruba lati bu ọna ate lu iwa ipa yi.

MAṢE JẸKI AWỌ ARA ỌMỌ RẸ BAJẸ

Awọ ara omọ re lọkan ko si ti gbo. Maṣe se omọ re di omikeru nipa lilo kemena ara re. Mentholatum awo alabo ara kemena ara o si agbara ara jẹki, fatu ati lati mu dan ghiarin Mentholatum o fun omọde ni alafia ati idunnu. Nwọn sta sinu awọn ide ati agolo bayi.

ATURA—TAWOSE—IWOSAN

Jeki Mentholatum wa ninu ile re nigbagbogbo-ra ide tabi agolo kan loni!

MENTHOLATUM

OGUN IPARA TI O DARAJULO

Awọn ti o nse ni Mentholatum Company Ltd (Est. 1889) Slough, England.

'ỌBẸ' KOLU AKINTOLA

IJỌBA TẸ ẸTỌ OGUNDE LOJU

Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ṣe gbangba fun aiye pe iwa ikorubajẹ, aiṣoto, itapasi ilana akọsilẹ ofin ati iwa ilo ipa ati agbara ẹni ni ilokulo ni iwa ti Ijọba Iwọ Oran hu lati gba ẹnjẹ lowo eleee ọmọ ilẹ wa, Ogbeni Hubert Ogunde.

Ogbeni Bola Ige, akowe ikede ẹgbẹ Afẹnifẹre so ninu ikede kan ti o fi se enu si ile ise wa pe o ti to ọgun odun ti elere akomolagbun Ogbeni Ogunde ti bere si ni se awọn ere. [illegible]

Ogbeni Bola Ige si se alaye siwaju ninu ọrọ re pe, Egbe osere Ogunde ti se awọn ere bi "Iseke [illegible] Ira (Ira valley coal mine incident) ti odun 1939, ti [illegible] odun 1945, [illegible] "Yoruba Ronu" [illegible]

Sugbọn Ijọba Gomina ko gbe ẹsẹ kankan ki awọn [illegible] akọsilẹ ofin di lati dabaru Ogbeni Hubert Ogunde ni akoko na.

Nisin ahoye Ogbeni Ige lori idi ti Ijọba fi gbe ẹsẹ le ẹre Ogunde ni Iwọ-Oran, o tẹsiwaju pe awọn [illegible] ẹgbẹ Omo-Olofin pe Ogbeni Ogunde lati wa se ere "Yoruba Ronu" fun won lojo ti awọn nda ẹgbẹ na sile.

Opo enia pelu awon ti o wa ninu Ijọba ni o fi ayọ se ere na si ni akoko na. Nisisinyi pe o pari lori eyi nikan, awọn omo ẹgbẹ NNDP ti wa akọle ere Ogbeni Ogunde "Yoruba Ronu" lati gbowo ẹgbẹ wọn.

O si se siwaju sii pe "lati igba ti awọn ti da ẹgbẹ NNDP sile ni ile ẹ o gbohungbohun ti Ijọba Iwọ-Oran ti bere si ni awe "Yoruba Ronu" lo [illegible]

Ẹgbẹ Afẹnifẹre wa ni [illegible] pe, iwa Ijọba yi je ilodi si akọsilẹ ofin ti o dabobo eto enikokan gegebi awon se ko sinu akọsilẹ ofin ilẹ wa". Agafi bi awon ba [illegible] kankan lati dawo Ijọba duro lori awon iwa wonni, "Eyi ni yio je ibere awon ọna ti yio pa ominira Iwọ-Oran da si Ijọba ipa [illegible]"

Idunnu

"O je ayọ lati ri pe Ijọba Apapo gba ẹgbẹ elere Ogunde laye lati ma [illegible] se ere na ni Eko, ati pe awon Ijọba Ipinle miran ko fi [illegible] idunnu si gegebi [illegible] yi kan si ẹgbẹ elere yi.

Ogbeni Bola Ige ti kori Aye Orile-ede yi, Dokita Nnamdi Azikiwe pe [illegible] Ijọba [illegible] ominira enikokan [illegible] yi ko di atemole labe atelese"

O si fun [illegible] Bakanna pe

Ikede Akintola ko gbayi

EKA "Awo Youth Brigade" Ibadan ti tako ọrọ ti Oloye Akintola sọ ninu ẹrọ gbohungbohun lana [illegible], nwọn si ti kesi awọn enia Ipinle Iwọ-Oran Naijiria pe, o jẹ ọrọ ati idi ti ko m'yan lati ati ọrọ ti awọn enia gbodọ lodi si.

Ninu ikede ti o jade ni ẹka ile ẹgbẹ na ni Ibadan ni ọjọ Aje ti ayọ ọjọ keta osu kerin ọdun yi, nwọn sọ ikẹka si ọrọ re na gegebi ọrọ ti o kojọ lati inu iwadi Coker.

Ẹgbẹ Brigade na kanu si atako Oloye Akintola lori Oloye Ọbafẹmi Awolowo ati Alhaji D. S. Adegbenro awọn gatit awọn ẹgbẹ mọ daju pe awọn jẹ ayanfẹ oṣelọpọ enia ni Ipinlẹ Iwọ-Oran Naijiria.

Ẹgbẹ na wa sọ pe ikede Oloye Akintola alaa apọn [illegible] lati fi [illegible] ye. Nwọn si kilọ fun awọn enia pe ki nwọn ma se jiki Oloye Akintola si awọn Iyan.

Ẹgbẹ na kesi Oloye Akintola [illegible] pe ki o lọ Ile Igbimọ Asofin Ipinlẹ yi [illegible], ki o si di ibo titun bi o ba jẹ wipe o daa loju pe nitoto ni awọn enia wa lẹyin on lẹhin ọdun meji ti o ti [illegible] re [illegible].

OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

Ẹgbẹ Dọmọnu jẹ abawọn fun iṣọkan

EKA ẹgbẹ Afẹnifẹre Ikole Ekiti ti kesi Oloye S. L. Akintola, olotu Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ki o tu Ile Asofin ka, ki o si pasẹ idibo titun.

Ni ibi ipade kan ti ẹgbẹ na se ni Ikole lẹna lọlọyi, ẹgbẹ na ko-mọnu si [illegible] awọn ijọye kan ti nwọn nfi agbara mu awọn enia wọn lati bọ sinu ẹgbẹ Dọmọnu (NNDP).

Ẹgbẹ na si se ipinnu idẹkẹ [illegible] si aṣiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oloye Ọbafẹmi Awolowo, ẹniti o nse ọwọn ọdun mẹwa lẹwọ [illegible] ati si Alhaji D. S. Adegbenro pẹlu si Oloye R. O. Arẹda ati aoju Ile Igbimọ Agba, Oloye P. A. Ogundipẹ.

Lara ipinnu ti ẹgbẹ na tun se ni igbẹkẹle ti awọn ni si awọn oloye agbegbe Ikole lori ikorira ati ẹgaba ọmọ ẹgbẹ Dọmọnu, nibẹ ti ọrọ iṣelu ko fi kan wọn lọwọ lẹsẹ.

Bakanna ni ẹgbẹ na ni ife gidi si ipapọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakuko. Ẹgbẹ 'Zikist Movement' papa ti fẹran kan Ijọba ẹgbẹ Akintola nitori ikorira, ifipamuni ati biba enia wa ọjọ gẹgẹbi ọna ti ẹgbẹ na ro pe nwọn le fi ri atilẹhin awọn enia.

Ninu ikede ẹgbẹ na, nwọn lodi si iwa Ijọba ẹgbẹ Dọmọnu eyiti nwọn fi gba oye lori Oloye Kola Balogun.

Ẹgbẹ na wa sọ pe awọn ẹgbẹ Akintola ti sọ abawọn si isọkan Yoruba eyiti ẹgbẹ na fi se idamare ẹgbẹ re ati pe ki ise ire isọkan bayi ati ọmọ Yoruba nwa.

Arẹwa Jẹbi

OMIDAN Arẹwa Naijiria odun 1960 ati osise ni ile ise "Telefison", Omidan Rose Mary Anieze jẹbi ẹsun meji ninu ẹsun meta ti olopa fi kan ni ile-ẹjọ kan ni Eko ni ọjọ Ru ti ise ọjọ kini osu kerin odun yi. Adajọ fi ofin de pe ko gbọdọ se ijọngbon latin ọjọ kan lori idaro ara re fun ponun medogbon.

Nkan [illegible] Omidan Rosemary pe [illegible] si alejada ati [illegible] olopa [illegible] ẹgba Ibadan Rosee [illegible] osu kerin odun yi.

Omidan Rosemary pelu enire Omidan Mary Nwakpu [illegible]

[illegible] Rosemary ati Mary ko lati [illegible] pelu olopa [illegible]

IGBARAGA RẸ

Ninu oro [illegible], adajọ gba pe olopa fi [illegible] Rosemary [illegible]

[illegible] Ogbeni G. O. K. Ajayi [illegible]

LẸHIN AWO, KO SI AṢIWAJU MIRAN

OLOYE R. Akinyẹmi ọmọ ẹgbẹ Alakuko kan ninu Igbimọ Asofin Iwọ Oran se gbangba fun awọn onirohin ni Ibadan ni ọjọ kejo [illegible] ọdun yi pe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni gbogbo ọmọ Yoruba nfẹ ni aṣaju wọn. O si [illegible] pe "Aṣe po ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakuko ati Oloye Awolọwọ gẹgẹbi olori nikan ni le da alafia, itura ati ijọba idẹra pada si Ipinlẹ yi. Eyi nikan ni o si le gba awọn enia Ipinlẹ yi lọwọ iṣọbadiyan ati ifaiya ti awọn [illegible] toria ti le wọn si labẹ Ijọba Oloye Akintola.

Oloye Akinyẹmi sọ ninu ọrọ re pe ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakuko ti gbaradi lati ja fitafita fun itusilẹ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ẹniti gbogbo ọmọ Yoruba mbẹre kikankikan lati je aṣaju ti yio ko wọn yọ lọwọ [illegible], ifigbira ati iwa ipa, idarudapọ ati ijẹkujẹ si oselu.

Oloye Akinyẹmi si ba ọna ete le Ijọba Oloye Akintola, o je apejuwe Ijọba na gẹgẹbi, "ti ba [illegible], ẹru, ati Ijọba janduku." O si se alaye siwaju si pe Oloye Akintola pẹlu iwa arekereke re ti o fi ko awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko [illegible] ẹgbẹ Dọmọnu (NNDP) re ti se ilẹri lati fun awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko na ni ipo alakoso. Ninu ilẹri re, o ti fi "eku kan re ọmọ meji," eyi ti ko je ki o gbaiya to lati sọ oruko awọn alakoso re fun aiye gbọ.

Oloye Akinyẹmi sọ siwaju pe gbogbo enia bojubọju ati arekereke ti Oloye Akintola ti Ijọba re nfẹ gba lati se idibo (bi o ba ṣe ye ni ninu ero Akintola, o nfẹ se idibo pajawiri ni Ipinlẹ Iwọ-Oran ki o to to akoko idibo si Ile Asofin Ijọba Apapọ ti ọdun yi) ni o ti han si awọn [illegible] ati pe awọn o pẹlu si ti mura lati da Oloye Akintola ni imu mi ni ọrọkọna ti o wu ki o gba.

Oloye Akinyẹmi wa ke ti gbogbo awọn lọsekokosẹ [illegible] ẹgbẹ Alakuko ati Afẹnifẹre ti o wa ninu ẹgbẹ miran lati pada [illegible] ẹgbẹ wọn lati [illegible] nitori kayi nitori aye si wa fun wọn, bi awọn ba [illegible] lẹhin lati ti [illegible] aye na ba ti, ko ni si aye fun enikan mọ.

Oloye Akinyẹmi wa bẹ [illegible] o si se gbangba pe "ẹni yowu ki ieu re bajẹ, ko kin awọn omo ẹgbẹ Alakuko Ipinlẹ yi nitorije. Awọn ti pari awọn ẹgbẹ Alakuko ati Afẹnifẹre, kii tun se pe a nfẹ ye po mọ, ati di okan ẹniti ko ba dun [illegible] o ninu ki o yan okan si lokokọ".

Oloye Akinyẹmi wa pari ọrọ re nipa kike si awọn ọba Iwọ-Oran lati kiyesi ara nitori ipo wọn ati iwọla. O si se itọkasi pe ki se eto awọn ọba ni nwọn igbati awọn kii se oselu lati yọjusi ẹniti awọn da duro ni ọna ise.

O si se itọkasi pe ki ise akoko ti oye ki awọn ọba maa pe na nje awọn ọmọ Yoruba ni yi nitori ẹyo ẹnikan ti [illegible] fun ri [illegible] Romewe lonaloloyi.

O si wa se itọka si awọn akoko ti oye ki awọn ọba ti fi ara wọn han ki baba ti nwọn ko si se [illegible]. O

(Wo ojuewe [illegible])

WOKO FEE SAN
Sun un bi omode

[illegible] **MENDACO** [illegible] **MENDACO** [illegible]

Osise Ijọba di janduku

OLOYE Samuel Ladoke Akintola, olori ẹgbẹ NNDP [illegible] Iwọ-Oran, [illegible] A.W.O.

[illegible] Oloye Akintola [illegible] Ekotedo [illegible]

[illegible]

Ifẹ Ẹkọ pa Ọmọ ọdun merinla

[illegible] Arikpo [illegible]

[illegible]

Oṣupdekanrin yi [illegible] Ogbeni Asu Arikpo [illegible]

[illegible]

A bubu [illegible] ọdun ti o kọja ni o jade ni ile-ẹkọ [illegible]

[illegible]

Ara-hihun, ara jijoni ati ara gigenije ti AWO-ARA TI KODARA

SIWAJU LEHIN

Ni agbegbe [illegible] Amerika [illegible] Ekara, Rore, Lapalapa [illegible]

NIXODERM je egbogi [illegible] NI-XODERM [illegible]

[illegible] Ma se jeki [illegible] Lo NIXODERM [illegible] NIXODERM [illegible] Ra NIXODERM [illegible]

NIXODERM

Igba ko lọ bi orere

Mo ki nyin o enyin ọmọ Yoruba
E ku asiko yi o ẹnyin ọmọ "karọ o jire".
Mo ki nyin ẹnyin ọmọ Oduduwa
Mo kan sara si nyin ẹnyin ọmọ ọkọ
Bi a ba ni k'a wi yio dabi owe
Bi a ko ba si wi yio dabi ija
E jẹk'a kuku sọrọ f'ọmọ ale, alaigbọran
K'a sọrọ fun ọwanrin-were k'o lọ wo'kan ṣe
Bi a ko sọrọ, nwọn o sọ pe ẹru nba wa
Bi a ngwo won ni'wo were nwon a sebi ejora lo mu wa
Igba ko lọ bi orere

O to ọjọ mẹta ti mo ng w'oye ile aiye
Ti mo ng sakiyesi gbogbo darudapo awon enia
Mo fowo lẹran mo nwo igboke-gbodo ọmọ enia
Mo rii sipe awọn tilẹ ti gbagbe Ọlọrun
Nwon nbọ enia bi ẹni bọrisa
Ki nwon o ba le ni ipo ati owo
Awon ẹdalẹ so ara won di alewi-lẹṣe
Nwon gbagbe pe Ọlọrun lo ni okunkun ati imọlẹ
Emi ti ko ri d'ọla ti ti ndamọran oṣu mẹfa
Agberaga gbagbe pe igberaga lo nṣiwaju iparun
Igba ko lọ bi orere
Nwon gbagbe pe igba ko lọ bi orere
Akọni loni le pada di akurẹtẹ lọla
Ọlọgbọn loni, a maa pada di di omugọ lọjọ miran
Omugo a si wa pada di ologbon
Bi enia ba gbagbe Olorun kii gbagbe
Yio ṣe 'ranti Awolowo yio si mu jẹri awon odalẹ
Awolowo sa ni ẹniti Olorun ran si wa
Lati gba Ipinlẹ Iwo-Orun la lowo Uku-uku

Nigbati awọn wọbia, alailayesi nlo awọn jandu-ku enia
Lati ma d ruba awọn olotitọ ati enire
A ko sa le fi agbara mu ara wa lati ronu
A ko le lo ifiyajẹni mu ni parapọ
Nigbati awimayehun ba si pade awi.i-gbọ
Ohun ti yio sele ni iparun
Awọn ni wọbia, ọmọ ale, to gbọwọ lowo uku-uku
Igba ko lo bi orere
E jẹk'a ronu jinle k'a to so pe Yoruba ronu
K'a mo iru awon enia ti ko ronu yato
K'a mo awon ti o ndu ti ara won nikansoso
Yato si awon to ng wa ire fun gbogbo ọmọ Oduduwa
O ṣe k'a mo awon to je pe owo, owo sa ni won nfe
Ti nwon ko bikita lati gbe iran Yoruba ta
Nwon ko bikita lati je ọmọ jaiye jaiye loni
Ki nwon si di omo jiya jiya lola
Oduduwa ko ni jẹki ti awon odale o s nwon
Atubotan awon 'o fi akaba ope goke tan to dalẹ ko ni dara
Igba ko lo bi orere
Ko ṣe nkankan bi enia fi eru l'owo
Ko ṣe nkankan bi enia fi eru ko oro jo
Ko buru b'enia fi ole gbe omo egbe re s'ewon
Ko buru b'enia ngmomo fi iya je alailagbara
Sugbon o ye ki eniti o ba nse iru ronu
Nitoripe ọda kan ko mo bi ọjọ ola yio ti ri
Riro sa ni ti enia, sise si je ti Olorun
B'o ti wu Olorun lo si nse iṣẹ iyanu Re
Iwofa baba eni loni le pada di olowo eni lola
Enit'o npoko esin ta a ma di eniti a npoko esinfun
Igba ko lo bi orere
Eniti ko ba iti ronu 'o lo ronu
K'a tete pada lehin awon olote ati odale
Ẹgbẹ ti awon ṣẹṣẹ da silẹ ẹgbẹ ọtẹ ni
Ko le p'ojo ko le p'oṣu ti yio fi tuka
Enikeni to ba tele won yio joe pelu won
Nitoripe nisisiyi ni gbogbo ireti won yio ṣegbe
Enikeni to ba mo pe on ni ife awon Yoruba l'okan
Ti ko fe ki ile Yoruba di gbigbemi ni orile e o wa
Ko si nkankan miran ti a le ṣe
Bikoṣe ki a parapo sinu ẸGBẸ OLỌPẸ
Igba ko lọ bi orere.

Lati owo —ẸṢỌ IKOYI

Awolowo ni Balogun oiwaju wa
Lati gba wa silẹ lowo eniti ko gbon to ni to fẹ mu ni l'ẹru
Igba ko lo bi orere.

Bi ko si Olorun, bi kosi Awolowo
Awon omo Uku-uku a ti ko omo Oduduwa lo
Aisinile ologbo ile wa di ti ekute
Ologbo si fẹrẹ de na t'ekute o di fifi panu
Bi aparo ba sa f'oju kan oloko, okoko ni ipa wọ'gbẹ

Bi obinrin ba gbohun oro nse ni yio ba buruburu
Bi a sọtẹ pa oloto ko buru
Bi a ba foju olore ẹni gun 'gi ki iṣe ewọ
A sa so Danieli sibo kiniun
Beni a gbe Shadiraki, Meshaki ati Abednego so sinu ina

Igba ko lọ bi orere
Nwon sọ pe ki Yoruba parapo, ki Yoruba ronu
Nwon fi ẹtẹ fọ ọgan Yoruba si opolopo ona
Nwon di Balogun l'okun lowo ati ẹsẹ
Nwon wa so pe ki awọn ọmọ ẹhin rẹ maa tẹle awọn

A ni ki ariwo tan nilẹ, nwon nfọla ẹkun f'agbọnrin
A ni k'a jẹkuru ọran tan, nwon tun gbọn 'wọ rẹ sawo
Egbinrin ọtẹ, bi a ti npa'kan ni ọkan nru.
Awọn ọlọtẹ ko gbọ otitọ ọrọ, ibi iparun ni nwọn nlọ.

Bawo ni Yoruba ṣe le parapọ
Nigbati are di ti Ologbo on ekute ?
Igba ko lọ bi orere

Iru iru wo ni a fẹ ki Yoruba ro
Nigbati ogun enia nderu ọdẹgbẹta

IWORA ATI IRORA LO

Nigbana ni o wipe mo dupe lowo

DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

Nwon ngmu arera/mu ati apo-ito re tun sise dada nitori nwon si nle gbogbo oro ti o nfa

IWORA, EHIN-DIDUN, IRORA ORIKERIKE-ARA ATI LAKUREGBE RE JADE

Nigbana ki irora re ti se lo awon koro egbogi DeWitt ni o mu o tokun ati agbara nibon nwon fun aje re se dada. Ra koro egbogi De Witt die nisisiyi ki o si ni ilera ati agbara re pada.

FUN ILERA ATI AGBARA

DeWitt's
KIDNEY & BLADDER PILLS
EGBOGI ATEJESE TI GBOGBO AIYE TI MO

Pa Ẹran to dara

Salamu Alekan, fun gbogbo enyin onigbagbo ododo. Iwasu mi one yi dasse loni "PA ẸRAN TO-DARA." Gegebi Olorun ti so fun Anabi wa Mohammad. (S.A.W.A) ninu Kurani mimo. Surate Saafati 37 aya 107 o ka 'boyi pe - "Aparu fun, Ohun Ipe, Totobi."

Jowo Iwo Olugbagbo ododo kiyesi filo ofin inu aya yi dada. Papa Iwo Olopa eran Ileya, Tokunsin, ati l'obinrin ti agbara ẹran pipa re wa fun, ẹran Ileya pipa dara fun Olugbagbo ododo, to gba Olorun gbo, ti o si nki wakati

Lati owo Alhaji Abdulli Baki Mohammed Iwo

marun pe, pelu ele ali re, ti o si je Olughare, ati Oloyo aakat nimo owo tabi oko, ti o si je Olu-ana omo-nikeji, somi ...u lowo, tagbara re si se, lati ra eyiti o ba jera, Eyo kan nio, tabi meji, tabi jube lo. Sugbon A n a b i Ibraim to da odun yi sile, eyo agbo kan ni o pa ti agbo na si dara, gegebi ayat ti a toka si yi. Iwo ti o pa eran Ileya tabi adaya, ti ope eran Itanran Adji, tabi suna-sint, gbodo ra eyi ti o dara. Agbo tabi Obuko, tabi aguntan, tabi ewure, ti odun kan pe le lori, ki Rakuoni na si dara ko je olodun mefa, ki malu si dara koje olodun merin, nu ninu re nigbati o ba paa tan, fun awon Eran meji yi, koje eleein alaluku Alamumara, elekeji Atsini

Awon Eran meje yi ni ko dara fun odun Ileya ati suna, ati Isin adji, ta npe ni adaya awon aiyi:-

1. Adajo eran tabi afoju eran
2. Alure eran
3. Amukun eran
4. Eran ti o ru
5. Ayaleti eran ko dara sugbon ti ko ba pe o dara
6. Arunwo eran ko dara ti ko ba ju Ilametalo o dara
7. Agbeti eran ko dara ti ko ba ju Ilameta lo o dara. Iowo so ... re ti o pa, lati ma dara pe, funfun ni o ba o lara mu ... dada. Oluwa yio fun wa ni opo odun se o, Amin o.

Awon omo ile Amerika melo kan ti nwon wa se e...

Irawọ atọsẹwai...

JUPITER ni irawọ ti o ṣe atọkun atosẹwaiye awon ọmọ ti a bi lakoko yi. Awon ọmọkunrin ti a ba bi lakoko yi yio ṣe iṣẹ ayeyori si rere ti won ba rin irin ajo lọ si idalẹ iba a ṣe irin-ajo lori ilẹ, lori omi tabi lofurufu ki nwon sa wa ni ọna ti o jina si ile tabi si ibiti a bi won.

Nwon yio jẹ ẹniti yio ma a dun ọda ẹgbẹ won ninu nipa iṣesi nwon si enia, eyi jẹ ẹbun lati ode Ọrun wa. Ṣugbon bi enia ba lodi si ilọsiwaju won won yio lodi si Oluwa re nikoja aala, beni, agbara eṣu ki yio lagbara lori nwon rara.

Nwon a si jẹ ẹniti imaa ṣe ikẹ awon o b i ti o ti won gẹgẹ bi ẹtọ ti olusin Ọlọrun ni lati ṣe si awon obi rẹ.

Nwon yio jẹ alafẹ enia, nwọn yio si ni igbagbọ ninu ilọsiwaju ọpọ enia nitori eyi, nwon ni lati sọra gidigidi fun ẹyẹ agbodo-sọrọ aje ni lẹhin ẹsẹ, ki o ma ba ṣe jamba fun won.

Obinrin ti a bi lakokoyi yio jẹ iyawo rere ati iya pataki pelu, ṣugbon ki ama kuro ni ile ọkọ kan bọsi ikeji ko dara fun nwon rara.

IṢẸ ṢIṢẸ

Nwon yio ni ifẹ si ẹkọ iṣẹ ijinlẹ ati aworan alaf'ọwọya, ṣugbon eyi le ma ṣee ṣe to bi yio ti wu won to, (bi nwon ti fẹ ẹ ko o to) nitoripe aisiki owo sile yio ja w o n niro. Iṣe alamojuto alaisan ninu ile iwosan nla dara pupọ fun awon obinrin ti a bi lakoko yi. Ṣugbon, ati obinrin ati ọkunrin ti a bi lakoko yi ni iṣẹ olukọni dara fun pupọ, bẹ na si ni

nikẹhin, ... ẹniti a b... o fẹ ọkọ ... ti a b i l... Scopio, ... awon mej... igbadun.

AKOKO ...

EYITI ...
Nwon yi... lakoko ti ... ore ati ... lode, ṣug... yio se iṣẹ ... ti irawọ ... lode.

II...
Ko si ...

Lati ọwọ Em—El–Dad–T...

iṣẹ ateto ile iṣẹ ati iṣẹ olubẹwo t a b i oluyewo ile iṣẹ iṣẹ to gboro ma tun dara, lopolopo.

IGBEYAWO

Yio jẹ imọran pataki fun ẹniti a bi lakoko yi ki o tete gbeyawo, nitoripe abuda rẹ nfẹ ọrẹ ati olufẹ, p a p a nipa iyawo fifẹ, nwon y i o fẹ ọpọ obinrin tabi ọpọ ọkọ ki nwon to le ri ikan t i won yio dimu won nipa ... ṣugbon ki... si arun k... rara, ikilọ... nwon ni ... tọju oku... daradara ... le ṣe e... dagba d...

Alapara Ibadan

(Lati oju ewe keji mu re adi odiodin. Ti nwon ba ni ki omoran mọ ọ nse ni i mọ ọ toto o sebi owe o. Alapara, o ki se ọmọde ninu ijinle Yoruba o ti ye ki ohun ti mowi yeyin o

Alapara Oti ṣe mi o. Ibiti e ko de tite ti soro mo ti mo de ibe o.

Kanṣelọ 'B' Nisisiyi mo ti f'okankan gaan mo si ti jawọ ninu apọn ti ko yọ. mo ti da omi ila ka ina. Mo ti kuro ninu egbe "Dọmọnu".

Alapara Nwon ko to tẹle, paapajulo Judasi ti nse Olori won, bi o ti kuro ninu egbe won yea ni o dara.

Kanselo "B" Eko tilẹ le tẹlẹ wọn se awon alagemọ oselu ni ngo wa tele ? Larin ọdun Kansoso ni nwon da egbe osela mẹta atunbọtan awọn egbe na si ja sofo.

Alapara Tẹlẹtẹle egbe na ko tile le ri di joko ni Naijiria, kama tile so ti Ipinle Iwo Orun toripe awon alaidara oselu ni nwon da sile lati ba le ko awon omọ Yoruba ta fun Gambari.

Kanselo 'B' Kaṣi ma a woye na, ṣugbon mo mọ daju pe, o pẹ o ya ni ibo didi yio waiye ni Ipinle Iwo Orun nigbana ni AKANTANLA ati awon alafẹhinti NNDP yio to wa mo iran won ninu awo.

Alapara Ao pade layo o kanṣẹlo mi owon. Awọn mejeji si dagbere fun ara won pe odigbose.

Olotu Enikeni ti mọ pe nse ri awon enia ntan egbe NNDP je ti nwon fi so pe awon nse egbe won. Ori ese were o ko bu s'ogan ni oro won. Owo ti nwon nfon kakiri lati ra awon omo egbe AG ati NCNC ni awon enia se nsunmọ won. Ki olukuluku enia le ri tiwon je ki egbe won to ku.

Alapara Akatanla ti o tile nda Ipinle yi ru nko ? Nibo ni yio sa gba nigbati eku ida Ijoba ba t u n bo si AG lowo ?

Olotu Oni potimonto ni jagunlabi ti o daruko yen, ti o ba di karangidi, yio gbona Oke Oya lo lati fi ibe se ibugbe ni.

Alapara E ko puro Olotu sebi "Sango ni o bi igo" toto o sebi owe o. Sebi Gambari ati F u l a n i egbera ni won ise. A wa je pe AKANTA LA papa de ile gan an.

Olotu Pe e mo ti wi yea o Alapara "Eleṣe ko yio lo laiko jiya ese re." ofin Oluwa ni, ko si le yi'ada lailai.

Alapara Oro ti Ogbẹni Ogunde tun ti je ninu oro iselu ? sebi ere aladun re ni o nse kakiri fun ati ma a ri onje ojo re je, ki o si le ma a sanwo ori re lasiko.

Olotu Ore ti o ba ti koja ekun erin ni a fi nrin Owe ni o. Kasa ma a dake nipa ọrọ ti Ogunde. Ajala tani na o ? Awon ta nwi na ni o, ka fi ire pade lose to m'bo o Alapara.

'Ọbẹ Ak...

(Lati oj... bere pe k... ṣe:-

"Nigbati... oselu yo ... tẹ Oyenu... ile ọkọ g... Ifẹ.

"Ti irin... ile ẹkọ g... awon dadu... nitori ẹsẹ... pe nwon ... Oloye Aki... Ipinlẹ y... awon oba...

• Gbigb... Kọla Bal... akowe egb... fi "egbe... da silẹ la... ominira ẹ...

• "Nwọn ... lẹsu egbe ... "ojulowo ... nipa gbigb... rẹ nitori e...

• "Baka... ọba ko lo... ri sọ si ... O. Dina ... ṣẹhin ni Ib...

Oloye A... pari ọrọ r... awọn ti o ... sinu ipelẹ ... Yoruba su... ẹnikansoso ... oba lore la... Ijoba Apa... awọn ọba ... lọ mu ọw... iselu.

nwon wa se ere aladun ni Naijiria ni odun 1961.

Yoruba ko egbe Akintola

Ipoti

Eka egbe Afenifere ni Ipoti Ekiti ti kesi awon omo Yoruba pe ki awon gba ara won sile lowo awon oselu ti egbe na pe ni aja Gambari. Egbe na so ero yi ninu ipade ti nwon se laipe yi.

Egbe na kesi egbe Akintola ti peni Demo lati vi oruko pada si Agamo nitori pe gbogbo awon oselu to wa ninu egbe Akintola na ni o nyi egbe oselu pada lojojumo nitori owo Agemo ni o ma nyi awo pada nigbakugba.

Ninu ipinnu egbe na, nwon se wipe kosi ohunkohun ti o le mu awon yese ninu egbe Afenifere nitoripe ke si egbe miran ti o le fe awon me kunrin lorun bi ti egbe na.

Egbe na se apeale Oloye Obafemi Awolowo gege bi asiwaju rere, ti o ti se ohun ribiribi fun ile Ekiti ati Ipinle Iwo Orun. Nwon ro Oloye Awolowo lati ranti pe "Bi ekun ba pe titi di ale, ayo mbo lowuro" Bakanna ni nwon gbadura emi gigun fun Oloye Awolowo Egbe na wa pe Oloye Akintola ni ija lati tu Ile Igbimo Asofin ka bi o ba je wipe otito ni awon eni Ipinle Iwo Orun gba egbe Domonu NNDP lowo re.

Ki ipade na to pari egbe na so pe awon ni gbekele Ekun ninu Oloye Obafemi Awolowo, Alhaji D. S. Adegbenro ati awon asoju egbe Afenifere re omo Ekiti ninu Ile Igbimo Asofin ni Ipinle Iwo Orun ati ni Eko.

IDANRE

Ninu ipade Lasiti eka egbe Afenifere se ni ilu Idanre ni nwon ti fesi si ero Oloye Akintola ayi ti o so lori ero redio ni ojo keta osu kefa yi nibi eyi ti o ba Oloye Awolowo lakoko tire dan? Awon omo ile iwe re fe se dan? Owo kuku, ta lo ge?

Gbogbo ipade yi ba ese ate lu Oloye Akintola ati Oloye Fani Kayode ti nlo agbara ti awon adibo ko fun rara.

OKA

IRO patapata gbaa ni irohin kan ti o nja ranin ranin kakiri ilu laipe yi pe Olubaka Oke ati awon Oloye merinla ni Oka agbegbe Owo ti faramo egbe NNDP

EGBE DOMONU JI OWO OLOWO

Egbe W. M. B. C. ti jewo pe, awon yio tako NNDP nipa lilo amin 'owo fun idibo ni ipinle Iwo Orun' tabi ni ibikibi ni Naijeria, nitoripe awon ti jeki amin owo yi di mimo lati ojo pipe fun ijoba pe on gan an ni awon nlo fun idibo.

Ogbeni M. D. Iyorkase ti ise asoju owo egbe UMBC kuuyi si ile Igbimo Asofin Apapo se pe, awon ko fi se nigbo Igbimo Aoba Apapo eto idibo po, ki nwon lete ye ara NNDP na wo, ki o ma ba di okan o ye sa adenuyede ate nina ibo ti o nbo ni ojo iwaju. Orisi esun aisiru si Ogbeni Iyorkase si fi kan NPC pelu Akintola.

Akintola.

Ogbe. I. L. A Olukoju ti ise Asoju Owo ni ile Igbimo Asofin Ipinle Iwo Orun ni o ja di iro na, o ni egbon arodaroda ni awon kan nda labele, ki awon enia ba gbagbo pe egbe NNDP ri idi joko ni Oka.

O ni, awon enia Oka si faramo egbe Olope ati Oloye Awolowo titi di isisiyi.

Awon Oba duro gedegbe

Awon asaju oba Ipinle Iwo-Orun Naijiria mejila eyini Olola Adesoji Adeyemi, Oni ti Ife se asiwaju re to ni Ilu Ibadan ni ojo Aje ti ise egbonje osu keta odun yi pe awon ko ni owo ninu egbe oselu kankan.

Awon oba na fi kun pe ise atilehin fun Ijoba ode ko se pe ki awon ninu oro egbe oselu.

Ìwewaiye enia

PISCES
Feb. 20-Mar. 20

AWO TI O DARA:- Ofefe ati Kubusu
AMI ORI RERE:- Okuta pupa ni eyi je.
OJO TO DARA:- Je ojo Abameta

nikehin, o si dara fun eniti a bi lakoko yi ki o fe eko tabi iyawo ti a bi lakoko won-i Scopio, Cancer, ilopo awon mejeji yio si ni igbadun.

AKOKO TO DARA ATI EYITI KO DARA

Nwon yio sori rere lakoko ti Gemini, Cancer ati Libra ba wa lode, sugbon won ki yio se ise tuntun lasiko ti irawo Scopio ba wa lode.

ILERA

Ko si wahala fun

ti owo -Dad-Tawa

won nipa aile ara rara, sugbon ki se wipe ko si arun kankan lara won rara, ikilo ti o wa fun nwon ni pe ki won toju okun emi won daradara ti nwon ba le se eyi nwon yio gbadun dada.

AWO REE, IDERA REE

Egbe odo "Roma Youth Front" fun kesi Dokita Nnamdi Azikiwe, Are Naijiria lati fi to gbogbo agbara re sinu ofin eto esin orile-ede yi lati da oloye Awolowo ati awon elewon oselu miran sile pelu re.

Egbe na so pe Ipinle Iwo-Orun pupo Apapo Naijiria ti ko sinu ipinnu lati igba Oloye Awolowo ti wa ni ihamo.

'Obe' kolu Akintola

(Lati oju ewe keta)

bere pe kini awon oba se:-

"Nigbati nwon fi ote oselu yo Ojogbon Victor Oyenuga kuro ni ile eko giga Unifasiti Ife.

"Ti irinwo awon omo ile eko giga Ilesha ti nwon daduro ni ainidi nitori esun ti ko rinle pe nwon pariwo mo Oloye Akintola, Olotu Ipinle yi, ko gba Isosi awon oba.

"Gbigba oye Oloye Kola Balogu igbakeji akowe egbe Omo Olofin "egbe ibile ti nwon da sile lati se itoju ominira eniikokan."

"Nwon gba onje tenu egbe elere Ogunde "ojulowo omo Yoruba" nipa gbigbe ese le ere re nitori etanu iselu.

"Bakanna ni awon oba ko lo ip won lati ri to si ipo Oloye I. O. Dina ti nwon fa sehin ni ibi ise ijoba."

Oloye Akinyemi si pafi oro re pe gbogbo awon ti o ti fara ba ninu iselu wonyi je omo Yoruba subon ti eyo enikansoso ni o ta awon oba lore lati fori Olotu Ijoba Apapo o si kesi awon oba pe ki nwa lo mu owo kuro ninu iselu.

IDANRE

Ninu ipade Lasiti eka egbe Afenifere se ni ilu Idanre ni nwon ti fesi si ero Oloye Akintola ayi ti o so lori ero redio ni ojo keta osu kefa yi nibi eyi ti o ba Oloye Awo-

Ogbeni Akin Deko

lowo pe on le fa ijoegbon ati sirise si Iwo Oyan, Ipade na sope o je iyalenu fun won pe Oloye Akintola le la enu re so iru ero be yen.

Nwon ni nigba ti ki o mo daju pe odun m kanla gbako ni Oloye Awolowo o se Olotu Ipinle yi ko si ijoegbon ko si sise pajawiri rara. Lakoko toj yi ni gbogbo idun dorewore wa ni Ipinle yi.

Egbe na bere lowo Oloye Akintola bayi: Nje owo wa

NOW-ROLLS-ROYCE 707s ON THE LONDON RUN



Eto irinajo ayarabiasa ti ojojumo

NIGERIA'S oko ofurufu titun ti a npe ni Rolls-Royce 707 ti wa fun awon onirin ajo ti o nlo si Londonu ati awon ile Oyinbo. Rolls Royce ti a mo jakejado aiye fun ero ti o dara julo ti o se ero ti dagbe oko ofurufu yi fo bi eiye Fun igbadun ati itura nigbati o ba arin irin ajo ninu oko ofurufu ayara bi asa, kesi Travel Agent re tabi ki o bere ni Nigeria Airways Booking Office ti o wa ni Broad Street, P.O Box 136, Lagos (Telephone 26811) ni Bank Road, P. O Box 11, Kano (Telephone 3891) tabi awon ile ise oko ofurufu ni agbegbe re.

NIGERIA AIRWAYS
NIGERIA'S NATIONAL AIRLINE

OLOTU MI OWON

Iwe pataki si Akintola

Olotu Irohin Yoruba.

Jau mi yio dun ti o ba le gba mi laye lati ko iwe si Olotu Ipinle Iwo Orun Naijiria, Oloye S. L. Akintola lati bere awon oro die ti o je anfani fun mi wipe awon oro ti [illegible] lori re.

Olotu mi owon.

A! Olotu, [illegible] lo je fun mi nigbati mo gbo gbogbo oro ti o so nina oro awotan [illegible] ti o kejo, kini Awolowo ti se o tobe? Abi Awolowo ki ise Yoruba ni? Olotu se bi o so wipe [illegible] kan ni [illegible]? Bawo ni o se le yi be nigbati o ba [illegible] Awolowo olori egbe kan ni Naijiria, ti o tun je Yoruba ododo nile?

O ya mi lenu nigbagbogbo wipe ti o ba ti [illegible] oro [illegible] ti o [illegible] egbe Olope [illegible] o ba wipe nigbati o ko [illegible] awon o ma dan owo [illegible] si apo egbe Olope [illegible] O tun so wipe nigbati o ko fi awon [illegible] ti o fi han wipe NIPC je Ijoba ni owo bi egberun lona egberun mefa ati [illegible] ti o tun je ki [illegible] ghona. A! Olotu, [illegible] ko je bi? [illegible] o [illegible] ori oye Olotu, o so wipe nigbati [illegible] (Awolowo) ti o gba ipo fun [illegible] owo na bi o jeki o ni anfani lati ge owo ori si poun kan ati sile metadinlogun abo (£1: 17: 6d). Olotu [illegible] ni ko [illegible] mo si emi. Ninu egbe wo ni o wa nigbati Awolowo nfi [illegible] wonni? O so wipe Awolowo ki [illegible] ti o ba se han awon egbe [illegible] ati wipe o gberaga ju. [illegible] ki iba fi nkan han egbe, eyini ni wipe ko fi oro re han egbe ki o ko yan o ni Olotu? O ma ye ki a mo ohun ti a ma nfi enu so.

Oba mewa igba mewa. Ni odun ti o bo si ori oye Olotu bena o ge owo koko ti o si je ogbon oke (£7: 10s) si oke mejidinlogun (£4: 15s) kini o wa ti je? O tun kun owo ori si oke mejidinlogun (£4. 10s). Awon nkan buburu ti o je ota [illegible] se to dede asiko re bayi. Olotu? Ki a le onise kuro nbi ise, ki aja ni Ile Asofin ati ki a ma yi lati inu egbe kan si ekeji ati si iketa, se je dede asiko re?

Olotu, o so wipe Awolowo ko ni emi idariji, nje iwo gan na le dariji eniti o fe gba ipo mo o lowo gege bi asiwaju egbe NNDP ati Olotu? O so wipe o yoo Oloye Nje awon Ijoye ti nwon yo bi ota mefa si asiko yi ati awon ti nwon yo kuro ninu Igbimo Loba-loba je ise owo re?

Olotu mo fe ki o mo wipe o le tan awon kan je ni igbakan, sugbon o ko le tun gbogbo enia je nigbagbogbo. Bi o ko ba feti, o jebi gbolohun. Ki o o ki gbogbo egbe re.

Emi ni ore re,
'Jide Kehinde,
Oluponna-Iwo.

Ogunde, dara le

O di ojo ale ki alaburada to mo wipe oro odi ni on ru. Bi a pe titi, awon odun yio ku ola.

Aw o owe mi [illegible] yi wa fun awon elegbe [illegible] ati egbe [illegible] ti nwon npe ni egbe Domonu ti nse Ijoba Ipinle yi lowolowo pelu ogbon ewe.

A gbo ti gbogbo stelin-wa.

Ewo tun niti ojo meta yi ti awon tun nda egbe Onijo Hubert Ogunde duro lati se ere kankan? Sebi ara lu nfu won.

Ogunde nse faya Mid-west, Lagos ati Ila Orun tire ni nse. Ogunde ma faya ara lo fu won. Bi o pe titi ole [illegible] yio wa ye ni Ipinle yi ti gbogbo egbe, yala egbe Domonu ti awon npe ni Demo ni o tabi egbe kegbe miran yio lofi wa won fun fun awon enia ti awon yio si mo ni enia se ni ife awon si.

Asaju wa, Oloye Adegbenro ni awon enia mo ni olufe Yoruba nitoto yi. Ere nla wa fun wa lojo iwaju, nigbati egbe Olope yio tun gba Ijoba pada lowo awon omo lehin Egbe Olomi Foke Oya.

Ti Akintola ba to ki o tu Ile Igbimo Asofin ka, ki a se nibo tun tan Nigbana ni yio to mo wipe eke ati odale ni awon ioye ala-ti lehin on.

Gegebi mi, Ile mi ati iju mi ni Ile Ife, egbe Olope ni awa yio se ku porogodo, e ma se kobi ara si awon kan ti nsan ni Ife ti faramo egbe Domonu.

Emi ni
Young Popular Joe
Ile-Ife.

EGBE OLOPE DARA

E jowo, e gba mi laye die ninu iwe Oloyin momo Irohin Yoruba ti o njade losose lati kosi Oloye D. S. Adegbenro lati mu suru ki o si duro di ojo iwaju bi o ti wu ki o le to, egbe Afenifere ni yio bori ninu ibo ni Ipinle Iwo Orun.

Mo fe ki o gbekele Oluwa awon Omo Yoruba ni'le loko ati ni ajo paapa ni Ilu ILUTITUN OSORO duro gboningbonin lehin re. A si duro de ojokojo ti ibo yio de

Ko si ohun ti ole mu awa omo ILUTITUN OSORO kuro lehin Oloye Obafemi Awolowo, awa ko le tinu Imole bo sinu Okunkun, Eniti o ba ko egbe Olope Sile ni Ipinle Iwo Orun, o di eru awon Gambari titi aiye re. Awa duro de Oloye Awolowo bi o ti wu ki o pe to Ogun Odun nbo wa ku ola.

Awa omo egbe Olope ti Ilu titun Osoro ki Oloye *D. S. Adegbenro* pe o ku Idele Babasale wa. A be Olorun pe ki o ba wa gba Babasale wa lowo awon enia buburu.

Emi ni
S. O. AKINROTIMI
ILUTITUN OSORO

Egbe Akintola je okuta idigbolu fun isokan

OLOTU, inu mi iba dun pupo ti e ba le gba mi ni aye die ninu iwe Irohin Yoruba pataki yin oloyin momo ti nji-de losose lati ke si Oloye Akintola pe iru iso kan wo lo nfe fun awon omo Yoruba, ti o fi je wipe igbe isokan, isokan lo nke kiri?

Nje otito kan wa nibe pe Oloye Akintola nfe isokan larin omo Yoruba? Asehinwa asehinbo, Oloye Akintola ati awon amuegbalegbe re na lo nfo isokan awon Yoruba.

Eniti o nkigbe isokan yin ganan lo je okuta idigbolu fun isokan, on kan yi lo nse oke, to nse odo, on kan na lo nko awon janduku kakiri Ipinle yi lati ma ba dukia ati lati ma fi iya ti ko to je awon enia to lodi si Egbe Domonu to sese da sile lehin ti Omo Jangidi re ti jona.

Se awon ti nwon sa logbe tabi ti nwon lu ni ilukulu tabi awon ti nwon ba dukia won je ni inu won maa dun si iru ipo ti awon janduku Egbe (NNDP) Domonu fi won si ti won ni awon wa ni isokan pelu iru iwa ipa bayi?

EGBE DOMONU SINA

Mo wa ke si Oloye Akintola ko ranti pe ojo kan nbo sa o, ti akuko yio ko lehin okunrin ti yio ku iwo pelu iwa re o Gbogbo ohun to ba fe, gbogbo agbara to ba ni sa ma lo bo ba ti fe, sugbon ti Oluwa ni ile ati ekun re o, ki o si ranti pe Edamare ju eda lo o.

Eyin omo egbe NNDP) to wa ni Ile Igbimo Asofin Ipinle yi ati ti Ijoba Apapo, e mase ro pe e fi ibi su olore, ti elesan lo ju o. Nibo ni arakunrin yin wa? Enyin jodi jeso omo araiye ti nro ti oni nikan? E ranti ehin ola, owo ntan ati pe ipo na si ndopin, sugbon sa ranti pe iwo yio je ise owo re, iba se rere tabi buburu, sugbon nigbati o ba di ojo ikehin kini eo fi jihin fun Eleda

Mo wa kesi enyin omo Yoruba gidi pe ki e duro je ki e si ba okan yin so ro, ki e si mo pe Egbe Olope nikan lo le gbewa de ebute alafia. Ki e ranti pe bi ekun ba di ale kan, ayo nbo li owuro o.

Osise ti nwon da duro lenu ise won, ara isokan na ni yen. Ti awon oba, ijoye ati awon Minister ti je? Seti won ko ba hu iru iwa be yen isokan ko le si ni?

Iru elere Ogunde to ti nse lati bi ogun odun sehin, ti awon Ijoba Ipinle yi si pe lati wa sere fun won lo tun wa di eniti ko tun mo ere se mo yi ti o fi di pe nwon tun fi ofin s'omo d'eru da l'owo ko ninu ere re bayi, ko buru sa o. Ti eniti o kegi lo ju o. Beni ti ika lo si soro, ore otito ko si mo

Baba Layinka gbe yin goketan o tun la yin loju tan o wa di eniti ko mo o se mo loni, Oba adake dajo a da o. Tete j'oro ki o ma ba je pe ni ti egbe NNDP. Nigbati o je pe ile ti a ba fi ito mo iri ni yio wo o.

Ogorun odun ki ise titi lai, Baba ni Ikene fere de, ki Olorun ma sai gbo layo ati alafia. Enu ti Igbin fi bu orisa na lo tun ma a fi tubi. Baba fere de. Ologinni to rajo lo mu ile di ile ekute NNDP kere si Egbe Olope ati Oloye Obafemi Awolowo. Omo igba ki i ridi joko, NNDP ko le ri di joko ni Wesi loju Egbe Olope

O digba,
Emi ni,
Aiye-ureti Eleya.
Ibadan.

OLE TO GBE KAKAKI OBA

MO be olotu Iwe Irohin Yoruba ki o gba mi laye lati so awon oro wonyi sinu iwe re oloyinmomo.

Toto se, o se bi owe, Beni, awon baba wa amapaa owe kan bayi wipe "ole togbe kakaki oba nibo ni yio gbe fon?" Nwon a si tun ma paa bayi wipe: "Banigbe ki iya'na, aborisa kiisun otutu, o sun ni'le fogo ti kogbodo gbo ariwo, inu yara kanna ni awon meteta yio si sun"

Gere ti ile su ti Aborisa wonije je tan ni o bere si sa Igi jo ti yio fi ye'na. Bi o ti nse eyi ni Bamigbe bere si kilo fun u wipe ko gbodo da ina, nitori wipe on ko gbodo yena sugbon Aborisa ko ko ibi ara si oro Bamigbe; Osunni'le fogoti, ti fi ogo re ti si origun ile osi ti sun.

OLOYE AWOLOWO
Asiwaju egbe Ile Yoruba to gbayi.

Nje ki Aborisa na da ina re ni Bamigbe ba da ina ru Nipa be ija bere, nwon si fi ariwo bonu,

JAMBA SE OLE

Bi awon se nkigbe yi ni Osunnile fogoti ti ko gbodo gbo ariwo ba taji, ni o ba na owo le ogo re, o si bere si lu won. Enyin enia, ohun ti mo fe fi ye nyin ninu owe na ni wipe, eyi ti a npe ni Aborisa, wa gege bi UPP, eyi ti a npe ni Bamigbe wa gege bi egbe NCNC Sugbon Osunnilefogo ti ni egbe Afenifere (AG).

Ohun ti mo fe ki e mo ni wipe bi o pe bi o ya Egbe Olope yio gba Ijoba re lowo awon Alagbase. O ti da ni loju wipe Akintola ati Fani-Kayode kole se Ijoba ca jinna ti nwon yio fi pin gari.

Nigbana ni Alhaji Dauda Soroye Adegbenro yio gba Ijoba re lowo awon Odale, onijekuje ope lu ti nwon tori owo ba ojo Iwaju je fun awa ara ti a nbo ehin.

Bi o ba je pe I e lodara, enyin niyen, eleda nyin nigen alajobi Yoruba niyen, Abo oro ni a so fun omoluwabi, Se enyin na mo die ni u iya ti Judasi je?. Judasi dale Jesu Ngbo oku erun, Iwo lo le dajo. "Adelabu ma sun asun pa iye o"

EMA GB'OWO ABETELE

Orisa meji ni owo; Akoko owo ti Olorun ba fi ife fun enia. Ekeji owo Setani (Esu). Mo fe si enyin Omo Yoruba, omo Alade, omo Odua mo daju wipe "owo gbigbona wa, owo alafia si wa, ti nfa emi gigun ti si fa alafia b ara, ti kiifi eli pani lojo iwaju.

Mo wa fe se ikilo yi fun yin dada wipe ki e ma se gba owo ti egbe NNDP ba fun nyin ki ise owo rere. Owo setani ni. Ti e ba gba owo na ti e si to ri re dibo fun won ni akoko idibo, enyin ni eo da ara nyin lel i lojo iwaju

Nitori ti won ba fun nyin nlowo tie si gba ti ena je "sari" ti eo fi gba awe odun marun gbako ni e je yen o.

E jowo omo Yoruba e sora n pa owo gbigba Oluwa ko ni fi owo gbigbona sike wa o.

KOSI ONA FUN NYIN

Mo ke si Oloye Akintola ati Fani wipe ki nwon tu Ile Igbimo Asofin ka ki a mo egbe ti awon enia ni ife si. Bi e ba ko lati tu ka asiko yin ko gbodo ju odun marun lo. Ona ti eo gba ni gba yen, ao ma wo.

"Ole ti o gbe kakaki oba ni oran yin ao ma wo ibi ti yio gbe fon E ma fi agbara yan ara nyin, e jeki awon mekunnu yan nyin si ori aga Ijoba. Ema dale mo, Igbehin odale kii sunwon temi bayi.

Ayotunde Akinola
Lagos

OJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

I L U	OJO 'RU APRIL. 15 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun Eko — — — —
Abeokuta	Ijoko Iberekodo Asu Wasimi —
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan Isara
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo,
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	Kokori
Igbajo	— — — — — — —
Iressi	Ọbada
Badagry	Ado-Odo Ilogbo-Ale

ILU OJO 'BO	APRIL. 16 1964 (THURSDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin,
Abeokuta	Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo —
Ibadan	— — — — — — —
Ijebu	— — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	Araromi — — — —
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	Iloro — — — — —
Iressi	
Badagry	Badagry Town

I L U OJO ETI	APRIL. 17 (FRIDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege Ikeja Ebute Ero Ikorodu
Abeokuta	Lafenwa, Oba- Obada, Kajola, Ajegunle,
Ibadan	— — — — — — —
Ijebu	Ikenne, Okun-owa Erunwon Omu, Mamu,
Ijesha	Ibefu Atikori Imushin Ago-woye Ijesha
Ondo Ati Eti Odo	Esa-Oke Ijebu-Ijesha Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	Oko — — — —
Ekiti	Oke mesi Ifaki Igede Ikole
BINI	Uromi
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	— — — — —
Iressi	
Badagry	

I L U OJO ABAMETA	APRIL. 18 (SATURDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo.
Abeokuta	Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku, Isabo Olode
	Aiyepe, Sagamu, Ita-osu, Ogere, Itele, It Iloti
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilora.
Egbado	Alagba Ilaro — — — —
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Ilogbo, Ishan.
BINI	Eke
Eti Odo	Kpaksang, Bomadi, Ekeremor, Toniga,
Igbajo	— — — — — — —
Iressi	
Badagry	Ojo, Ajido, Iworo

I L U	OJO AIKU APRIL. 19 (SUNDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Obun-Eko.
Abeokuta	Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi, Araro
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-odo
Ondo Ati Eti Odo	— — — — — — —
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	— — — — — — —
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	Kokori — — —
Igbajo	— — — — — — —
Iressi	Obada
Badagry	Ado-Odo, Ilogbo-Ale

ILU OJO AJE	APRIL. 20 (MONDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Mushin
Abeokuta	Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawo.
Ibadan	— — — — — — —
Ijebu	— — — — — — —
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloke
Ondo Ati Eti Odo	
Egbado	
Ogbomosho	Araromi — — —
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	— — — — — — —
Eti Odo	— — — — — —
Igbajo	Iloro — — — —
Iressi	
Badagry	Badagry Town

I L U OJO ISEGUN	APRIL. 21 (TUESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Agege, Ikeja Ikosi, (Epe).
Abeokuta	Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle
Ibadan	— — — — — — —
Ijebu	Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu Mamu Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha-Ijebu. Isara Imodi
Ijesha	Esa-oke, Ilase, Epe, Iloba, Iperindo, Imuroko, Ikeji.
Ondo Ati Eti Odo	Igbo-Egunre
Egbado	— — — — — — —
Ogbomosho	Oko ————————
Ekiti	Oke mesi; Ifaki; Igede; Ikole
BINI	Uromi
Eti Odo	— — — — — — —
Igbajo	————————
Iressi	
Badagry	

I L U	OJO 'RU APRIL. 22 (WEDNESDAY)
Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo — — — — — —
Abeokuta	Atan Agbado Ifo Itori Itoku Isabo Odeda Olode
Ibadan	
Ijebu	Aiyepe Sagamu Ita osu Ogere Irolu Itele
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilara,
Egbado	Alagba, Ilaro
Ogbomosho	
Ekiti	Ilogbo Ishan
BINI	
Eti Odo	— — — — — —
Igbajo	
Iressi	Eke
Badagry	— — — — — — —

Asọbade ere bọlu

DIVISION 1

Aston V. v Leicester	x(2)
Blackburn v Ipswich	1
Blackpool v Sheffield W.	2
Chelsea v Everton	x
Liverpool v Arsenal	1
Nottingham F. v Burnley	1
Sheffield U. v West Brom	2
Stoke v Manchester U.	2
Tottenham v Bolton	1
Wolves v Fulham	1

DIVISION II

Bury v Preston	2
Cardiff v Southampton	x
Leeds v Plymouth	1
Manchester C. v Leyton	1
Northampton v Grimsby	1
Norwich v Middlesborough	1
Portmouth Huddersfield	1
Rotherham v Derby	1
Scunthorpe v Newcastle	2
Sunderland v Charlton	1
Swindon v Swansea	x

DIVISION III

Barnsley v Mansfield	1
Bournemouth v Shrewsbury	1
Bristol R. v NottsCounty	x(2)
Colchester v Luton	2
Hull v Brentford	1
Millwall v Coventry	2
Oldham v Crewe	1
Peterborough v C. Palace	x(2)
Q.P.R. v Port Vale	x
Southend v Walsall	x
Watford v Reading	1
Wrexham v Bristol C.	2

DIVISION IV

Aldershot v Rochdale	1
Brandford C. v Oxford	1
Darlington v Doncaster	1
Exeter v Brandford	2
Gillingham v Newport	1
Halifax v Chester	x
Hartlepools v Chesterfield	x
Lincoln v Workington	2
Southport v Stockport	v

SCOTT. LEA. DIV. I

Aberdeen v Dundee U.	2
Airdrie v St. Mirren	1
Celtic v Hearts	x(2)
Dundee v Partick	1
Falkirk v Q. of South	1
Hibernian v E. Stirling	1
Kilmanock v St.J.stone	1
Rangers v Motherwell	1
T. Lanark v Dunfermline	2

SCOTT. LEA. DIV. II.

Alloa v Dumberton	2
Arbroath v East Fife	x
Berwich v Queen Park	x
Cowdenbeath v Morton	2
Hamilton v Brechin	1
Montrose v Albion	x
Raith Rovers v Forfar	2
Stirling v Stenhousemear	1
Stranraer v Clyde	2

Da Ehin-didun at Lakuregbe duro

IJEKUJE ati Imukumu wahala, se aisiju' otutu igbagbogbo ati awon kokoro arun a ma a ko sare ba awon Erre (Kidneys) ati Ile-ito a si so ito di olomi aisan rukuruku, ki a ma daji loru, ki itr ma a jo ni nidi ki ojugun ma a ro ni ki ara eni ma agbon, ki oju ma a su ki kokose wu tomutomu ati o darugbo ekun Ran awon Eree (Kidneys) re lowo lati fi CYSTEX fo eje re mo. Akolo re yio beresi ran awon Eree (Kidneys) re lowo lati fo omi aisan ati kokoro arun kuro kiakiase wa a beresi gbadun laotun. A se ileri pe a itelorun patapata tabi ki o ma sanwo re ti ko ba sise lodo apoogun fun awon Eree (Kidneys). Lakuregbe, Ile-ito.

IDIJE ERE IBADAN 'CITY ACADEMY' KỌYỌYỌ

Ogunlọgọ ero ni o wa si ibi ere idije karun ti ile iwe giga Ibadan City Academy' ti nwọn ṣe ni ori papa iṣere ti "Liberty Stadium" Ibadan ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu kẹrin ọdun yi.

Ere idije na ti nwon bere ni dede agogo merin abo pelu adura ati oro alaga to agogo meje ki o to pari.

Awon agbo ile merin ti o fi agagbaga ninu ere idije na ni, agbo ile Ado, Aresa, Mackell ati Olubadan. Agbo ile ti Olubadan ni o gba ipo kini ninu ere idije na; awon ni o si gba "Asa idije oludasile" ile iwe na. Eyi ni o di igba kerin ti agbo ile Olubadan ngba Asa idije na leralera. Oloye T. L. Oyesina omo Ile Igbimo Lobaloba Iwo-Orun ti o da ile iwe na sile ni o gbe Asa na ti nwon si pe ni "Asa oludasile" fun won fun idije ododun.

Awon agbo ile 'Ado' ni o ko ipakeji ti awon 'Aresa' si ko ipaketa, agbo ile Mackell ni o si kehin. Omokunrin F. Ogunkola ti o sa okoleluba bata fi ehoro ni o fi "ala" idije titun sile. On ni o si sa ere ju ninu awon okunrin. Bakanna ni omodebinrin Easther Abiola wa ni ipo akin larin awon obinrin ni ibi idije na.

Die ninu awon enia pataki-pataki ti o wa si ibi idije na ni Oloye E. A. Adeyemo, alaga ere idije na; Iyaafin E. A. Adeyemo, Oloye T. L. Oyesina, Iyaafin Oyesina, Ogbeni T. A. Fasoro, Ogbeni Lackbella oloko agba ile eko giga Islamic Ibadan, Ogbeni J. O. Rusewe, Ogbeni ati Iyaafin Olawumi Falodun, Ogbeni Mgbudi, Iyaafin F. J. Ojo ati Ogbeni Aiyegbusi.

OWE YORUBA

O Oju lari la nṣododo aṣehinde ni ko wọpọ ṣaṣa enia lo fẹ ni lẹhin, bi ako ba si ni ile, taja fẹran ni ifẹni loju eni

O Ọtẹ ni nmu ... pe aja ni fadeyi oruko ọmọ awo ni iṣe

P Pẹhinda ko ri iṣe ẹke foju pamọ ko ri bi aṣeni ti nṣe nfi ni iṣe

R Rọrọ ag o ni imu agbo niyi, ọla babi ni mu ọmọ yan

S Suru ni baba iwa, agba to ni suru ohun bogbo lo ni

Ṣ Ṣegan ṣegan iba dode koni ni lari, aṣọ abuni ki ipe meji

T Tulasi ni on ma ba o gbe oni ko si aye, gongo imu rẹ nkọ?

W Nwọn tun ọ lọbẹ o ni ntami si, o gbọn ju ẹniti o bun ọ ni?

Y Yanmuyanmu ẹbin gbẹti nṣe fuja ni ailapa.

ALỌ O ALỌ

Lati ọwọ J. P. Bakare

1 Egungun ori oke abija wara, ki sa mọ lọgbẹ, ki tamọ lọfa, ojiji ni nma nfi iku pa ọmọ olọmọ o
2 Koni ehin, koni erigi onj; agbado
3 Adiẹ baba mi laiye laiye, adiẹ baba mi laiye laiye owo ni nje ki ijọka o
4 O ra, ko ni idin o
5 Aran mọ lọ ka ila, ila suwaju rẹ bọ wa le o
6 O r u k u tinditindi, Arabi kangekange ijẹ ti oruku bi mọ rẹ kiki Akẹtẹ o
7 O f u n yinrin yinrin ado agba, orin na po ṣe adongba osa kẹbẹ kẹbẹ adongba mẹta lanpa, m e t a lamo ọmọ laito o
8 Kirinnbitin abo mi loju, ki iduro ki ... rẹ aya ni ama fi wọ o
9 Agba igunnu, aru ẹru ma so o
10 Ajeko ako jo ja o
11 Ọra kan nbẹ lẹhin kule baba mi laiye laiye o nbẹ ni bẹ laiye laiye, ara aiye kinrin, ero ọrun ki nrin ojojumọ ni ma ndan o
12 A pa adiẹ, ajẹ adiẹ, nigbati a ju egungun rẹ si ita oni kokoro nko ko.

ITUMỌ

1 Ina Elentiriki
2 Adie
3 Ejọ kọra
4 Ọjẹ
5 Ere yio
6 Olu
7 Ẹjẹ n ig, Igbin, Pa
8 Ọgọgo
9 Ọpẹ
10 Ọra
11 E o ọjẹ
12 Ikanun Igbin

Irohin Yoruba

Awọn ọba lọ dọbalẹ l'Eko ?

IKỌ awọn Ijọbalọba Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria lọ ke lọ ba Olotu Apapọ Naijiria, Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu kẹrin ọdun yi lori ohun ti awọn pe ni irẹjẹ ninu iṣẹ Ajumọṣe Ijọba, paapa ni ibi iṣẹ Ibudo ọkọ Relowe.

Ikọ awọn ọba na eyiti alaga Ile Igbimọ Lọbalọba, ọba Tẹwogbeye, Osemowe ti Ondo ṣe aṣiwaju wọn fi Ibadan silẹ ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi lẹhin ti awọn ọba ti fẹwọ si aba ilako "irẹjẹ si awọn ọmọ ilẹ Yoruba ninu iṣẹ ati ipo."

Aba na sọ pe ki awọn yan ikọ kan lati lọ ba Olotu Apapọ, Ọlọla Abubakar ki nwọn si fi ohun ti o kan ọba ati awọn enia Ipinlẹ yi han ninu atako ohun ti o lewu ti o si le ba irẹpọ orilẹ-ede Naijiria jẹ.

Ni asiko ti nwọn moro aba na, Ewi Ado-Ekiti, Ọba Aladesanmi keji ṣe itọkasi awọn iwe kan ti o jade lati odo Ijọba ninu eyiti o sọ pe ẹsan ẹya ati ikorira si awọn enia Ipinlẹ yi ti o wa ninu iṣẹ Ijọba Apapọ wa.

Ọba Aladesanmi sọ pe, eyiti o tun tobi ju ninu yiyan ẹyi kan soto ni awọn tun fi ninu iṣẹ Ajọ iṣẹ Reluwe.

Ekiti ṣata Akintọla

Ẹgbẹ Alakukọ da wariwari lu Akintọla

ẸGBẸ Alakukọ sọ ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ karun oṣu kẹrin ọdun yi pe o ti han si gbogbo enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria-iru iwa tani yio-mu mi, itenilọriba lagbara ati iditẹ mọ enia lainidi ti Oloye S. L. Akintọla fi ngbogun ti awọn ti ko faramọ lasiko ti o wa gẹgẹbi Olotu inu Ijọba ẹgbẹ Ọlọpẹ ati nisisiyi ti o tun nṣe Olotu miran ninu Ijọba ẹgbẹ NNDP.

Ẹgbẹ Alakukọ nfi eyi fi esi si ọrọ atako asan ti Oloye Akintọla fi moomo ba Oloye Awolowo jẹ lori ẹrọ redio ti o sọ ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹta oṣu kẹrin ọdun yi.

Awọn ẹsun eke ti Oloye Akintọla na fi kan an ni inakuna owo ijọba, ijọba lagbara, idi kanrangbon si, ẹgbẹ oselu miran ati awọn Ijọba Naijiria.

Ninu atikun ọrọ ti ẹgbẹ NCNC tun sọ, awọn ni:

Ti Oloye Akintọla ba ronu ara rẹ jinlẹ, o ye ki o le ro inu ara rẹ wo ki o si ran Oba Akran, Oloye Adeyi, Ayo Rosiji ati Oloye Odebiyi [illegible] ti o mọ [illegible] ti a ko daruko won nibẹ nisu ẹgbẹ NNDP nisisiyi. A fẹ ki o mọ daju pe ati awọn [illegible] enia Ipinlẹ yi pe ju ki o ti [illegible].

Oloye Akintọla ni Igbakeji Oloye Awolọwọ, nitori ibikibi ti o ba le purọ de ki o ma pa niwọ; ko si enia ti o le gba pe Oloye Akintọla [illegible] awọn elese.

FANI FẸSẸ F Ẹ

Awọn ti nwọn nfi abọn ẹsan jẹ eni mimọ ninu ẹgbẹ NNDP nisisiyi ni awọn fi jẹ igi lehin ọgba ọlọpẹ nigbati Oloye Akintọla si nṣe igbakeji babasale ẹgbẹ na. Fi fi ẹgbẹ Ọlọpẹ sile won ko le jẹ yi iwsi ati ifuwa won pada.

Ẹgbẹ NCNC sọ ododo pe, ẹgbẹ oselu yoku ko jiya labẹ Ijọba Oloye Awolọwọ bikose labẹ Ijọba Oloye Akintọla.

Nwọn tun tura anri iwa Oloye Akintọla pe lasiko Ijọba [illegible] Oloye Fani-Kayode ni [illegible] ti o si fi je pe de Amerika ni [illegible] lasiko ijọba Oloye Awolọwọ ni Fani-Kayode [illegible].

Ẹgbẹ na ni lasiko Ijọba Oloye Akintọla yi, ni awọn yara pe Dokita Okpara pada lati ilu oyinbo nitoripe Ijọba Akintọla ti da nkan ru ni Ipinlẹ Iwọ Orun, lati wa yọ Oloye Fani-Kayode ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ kuro ninu ajaga odo Akintọla.

Awọn alatilehin NCNC wọnwọn

"Ni asiko Ijọba Akintọla yi kanna ni idibo wole Ijọba ibile di rudurudu atigbe ẹnu ni awọn nda awọn ọmọ NCNC si ewon, ti nwọn si nfi awọn olopa ibile, Wolewole ati awọn Koto ibile da won rihoriho lobee gee ti Oloye Fani-Kayode fi fi igbe ta pe, enia ati eto daru ni Ipinlẹ Iwọ Orun.

Bawo ni Oloye Akintọla ti ṣe tun wa nao pe Ijọba Awolọwọ ni ko dara? Ni ọna ti o koja yi ni Ijọba Akintọla gba oye mọ Oloye Kola Balogun lori lasan [illegible] nitoripe ko faramo ẹgbẹ Akintọla, bakanna ni awọn si tun yọ kuro ni Ile Igbimọ Lobalọba.

Laipe yi na tun ni nwọn yọ Oloye M. F. A. Agbaje kuro ni ipo minisita nitoripe ko ṣegbẹ Akintọla. Kini nkan si ipo Rotimi Williams ati Alhaji S. O. Gbadamosi ninu Ile Igbimọ Lobalọba? eyi ni ibere ẹgbẹ Alakukọ.

Oloye Akintọla dunrunmo Oni Ifẹ. Nigbati ko faramo ẹni ẹnfa re bokanna ni o si nse si awọn Oba ti ko ba faramo pelu.

Lakotan eyi Oloye Akintọla iba fi soro bi ilu yio ti ṣe toro, nṣe ni o beresi durunmo Oloye Awolowo ti o mọ dajudaju pe ko ni anfani lati je ni kere ni aye ti o wa nisisiyi.

Ẹgbẹ na ni, ira iwa bẹẹ ko dara.

OLOYE AKINTOLA

NINU ipade kan pataki ti awọn aṣoju marun ninu Ile Igbimọ Aṣofin Ipinle Iwọ - Orun lati agbegbe Ekiti ṣe ni Ibadan ni ọjọ keje oṣu yi nwọn kilọ fun Oloye S.L. Akintọla ati Oloye Fani-Kayode lati dẹ ua fifi iwa jagidijagan polowo ẹgbẹ won (NNDP), nipaṣẹ awọn janduku ẹgbẹ won.

Awọn aṣoju na niyi: Oloye J. E. Babatọla, Oloye R. O. Awojo, Oloye S. Ade Oloyo, Ọgbẹni S. A. Akerele ati Ọgbẹni D. A. Atolagbe.

Awọn aṣoju na sọ pe awọn enia agbegbe Ekiti ki iṣe enijagidijagan nitorina ki awọn ma ko iwa ipa ti ẹgbẹ NNDP nbu ni awọn agbegbe miran wọ agbegbe Ekiti. Nwọn sọ pe soru ni awọn enia agbegbe Ekiti fi nṣe ohunkohun ti nwọn ba fẹ ṣe nigbati bi awọn enia kan ti awọn aṣoju na pe ni "Alagbara-ma-moro-baba-ole" ba kolu awọn enia agbegbe Ekiti, abajade rẹ ko ni ṣe ẹnu rẹ ati pe ira akọlu bẹ ko ni tan je, aje ko be ẹni kan soto, eni eji ni ei eji npa.

Awọn aṣoju na ba ẹsa ete le awọn aṣiwaju ẹgbẹ NNDP fun rudurudu ti nwọn da silẹ ni Ilesha laipe yi, awọn ti pe iwọ na ni inja fun awọn aṣiwaju Ijọba ti nṣe wọn iṣẹ akoso alafia.

Ninu apa keji ọrọ wọn, awọn aṣoju na rọ awọn ọlọpa lati ma ba aise ojusaju wọn lọ ninu iṣẹ won; bi o tile jẹ wipe awọn alagbara kan nbale lati sọ wọn di oluṣ amuwere.

Ni ipari awọn aṣoju marun na kilọ pe Ekiti ko gba gbere fun rudurudu nitorina ki awọn olutan oselu yi iwa jagidijagan wọn pada bibẹkọ nkan ko ni rogbo fun wọn ni Ekiti.

ỌBA ỌLỌWỌ DI AKỌWE DỌMỌNU ?

ORI OLOWO, OWO Oba Olagbegi ni Ọgbẹni Edward Jackal Osun ti iṣe olori ẹgbẹ Ọlọpẹ Owọ da ẹbi iwa ipanle ti awọn digbolugi ọmọ ẹgbẹ NNDP hu ni ilu Owọ le.

Nina ẹsun ti o fi kan Olọwọ ni ọjọ kejọ 'Ru ti iṣe ọjọ kejọ oṣu kẹrin ọdun yi, Ọgbẹni Osun ni, idirudapọ ti o ṣẹlẹ ni oju Olọwọ korokoro ti ko si kọ ibi ara sii ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu kẹrin ọdun yi mu ki awọn awọn ọwọ ilu Owọ ma bu ọwọ fun un mọ.

AGBODEGBA ẸGBẸ NNDP.

Olori ẹgbẹ Ọlọpẹ na ni, asiko ti Olọwọ fi ngbadun pẹlu awọn "oluwa" rẹ ninu afin ni awọn digbolugi NNDP bẹrẹsi ba moto, ati ile je kakiri ilu Owọ, ṣugbọn ko kọ ibi ara sii, eyi fi han gbangba pe, Oba na fẹ ki ẹgbẹ NNDP fẹsẹ rinlẹ ni Owọ.

Ọgbẹni Osun ni koriigbagbe ni ohun buburu ti o ṣẹlẹ ni Owọ yi fun awọn enia.

O ni, nwọn bu ile on ti o wa ni opopo 5, Oke Jama Owọ jẹ, bakanna ni nwọn si tun run moto Ọgbẹni S.M. Ogundele alaga ẹgbẹ Alakukọ Owọ womuwomu.

"Fun ohun ti o ṣẹlẹ ni ọjọ na, Ọlọwọ fun ramarẹ yio kabamọ, o pẹ, oya ni o," bẹ ni olori ẹgbẹ Ọlọpẹ na wi.

Ẹka ẹgbẹ Ọlọpẹ Owọ ti kesi Arẹ Naijiria Dokita Azikiwe ati Ọlọla Balewa pe ki nwọn dekun rogbodiyan NNDP nda silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun nisisiyi.

IWA IPANLE

Ẹgbẹ Ọdọ Afenifẹre ni titu Ile Igbimọ Aṣofin Ipinlẹ Iwọ Orun ka nikansoso ni o le mu alafia wa si Ipinlẹ na.

Ninu Ipade ti nwon ṣe kanna ni nwọn ṣe ti kesi awọn ọmọ ilu Owọ pe ki awọn lodi si ẹgbẹ NNDP.

Ẹgbẹ Okpara Youth Brigade" Ipinlẹ Iwọ Orun ni o jẹ ẹdun okan won nipa rogbodiyan ti o gbode ni Ipinlẹ Iwọ Orun lasiko yi, atipe o ṣe wọn ni anu pe, Oloye Akintọla ati Oloye Fani-Kayode ni Babasalẹ idasilẹ rogbodiyan na.

Ẹgbẹ na sọ si i pe, ọtẹ ti ẹgbẹ NNDP na nṣe ni Ipinlẹ yi ko kere.

Awo bẹrẹ ẹjọ ajabọ

(Bẹrẹ lati ọjọ ewe kini)

Ọlọla Bairamian ati Ọlọla Idowu Taylor.

Awọn agbejoro fun Oloye Awolowo ati awọn iyoku ni Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya, Ọgbẹni A. A. Adesanya, Ọgbẹni Olu Ayọọla, Ọgbẹni Yinka Ayọọla, Omidan Bisi Adebule, Ọgbẹni S. F. Olakunrin, Ọgbẹni Willy Efeeye ati Ọgbẹni T. O. Kellock lati ilẹ Gẹẹsi. Gbogbo won ni nwon ran Ọgbẹni Durand lọwọ.

Diẹ ninu awọn koko ẹjọ konsilorian ti Oloye Awolowo pe nawonyi:

O ni ẹwọn ti awọn je on si ti pọ ju.

O ni adajọ na si ọjọ na da nipa eleyi [illegible] awọn olori Ijọba kan Henry Oboari ati Anthony Oboh ki i ṣe adamurrasy [illegible].

O ni adajọ ẹjọ ni fun adajọ ẹgba na lati sọ pe ọrọ Sergeant Ọbafẹmi ba ọrọ ti Oboh mo nighati o han gedegbe pe [illegible] awọn olori Ijọba mejeji na ti si ata wọn.

O ni adajọ ẹjọ ni fun adajọ ẹgba na lati gba pe awọn awọn Olopa ẹlẹgbẹ ati wa ba mi Ikoyi fun eto "JAMBA NLA" lẹhin ti Oboh ti sọ pe enikeni ko ṣe ipade pelu rẹ lodi si ẹni kẹta ti Olawoi wa je gbe ni.

O ni adajọ ẹjọ ni fun adajọ ẹgba na lati gba ẹri Oboh ati Alhaji Imam gbo loke gbo ẹri kan nitoripe ọrọ na wọn ọn, lẹhin ighati on pupọ ti ri iwa aropọnda awọn olori mejeji na.

Ṣango da rogbodiyan silẹ

OGA ọlọpa kan, Ọgbẹni Iyare sọ ni ile ẹjọ kekere kan ni Ilesha nibiti awọn ọlọpa ti duro wamuwamu yika ile ẹjọ ni ọjọ kẹfa oṣu kẹrin ọdun yi pe Lamidi Ajadi "Ṣango" ni o koko da rogbodiyan silẹ ni Ilesha ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu kẹrin ọdun yi nigbati Oloye Akintọla, Olotu Ipinlẹ yi ati Igbakeji rẹ, Oloye Fani-Kayode de si Ilesha lati ṣe idasilẹ ẹgbẹ rẹ, Dọmọnu (NNDP).

Ọgbẹni Iyare ṣe apejuwe Ṣango gẹgẹbi ọkan ninu awọn ti nṣọ Oloye Akintọla nigbati o nlọ si Ilesha. O sọ ninu ẹsun mẹta ti awọn fi kan an pe Ṣango da ilu ru, o pa Iyaafin Roseline David Iare, o si tun ba ohun ija lọwọ rẹ, beni yi kanna ni awọn tun fi kan ọmọkeji rẹ Ganiyu Iyanda, ẹniti nṣe asẹ rẹ ni awamọto takisi nibi iṣẹ idagbasoke Iṣẹ Air Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

ARIWO 'AWO' GBODE

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Iyare eniti iṣe atọna awọn ọlọpa rogbodiyan meji lọri Ilesha, ti awọn si duro ni Ile-iṣe Amele nitosi Ile-ẹkọ giga 'Grammar School' lati bojuto ohunkohun ti o ba bẹ silẹ ni ọjọ na wipe, nigbati Oloye Akintọla wọ ilu Ilesha, ariwo Awo! Awo! Awo! ati Zik! Zik! Zik! ni awọn ọkọ ayọkẹlẹ ti o tele Oloye Akintọla atipe ni ojiji ni Oloye Akintọla ati igbakeji rẹ Oloye Fani-Kayode duro, ti Ṣango ati Iyanda nsare jade ninu ọkọ ti won.

O tun sọ bayi pe, Ṣango ni ẹniti o koko gbogun ti awọn enia pẹlu okuta, ada ati ake, ti Iyanda alara gbe kumọ ati ohun ija miran lọwọ pelu.

Ọlọpa na sọ wipe Ṣango ni o fọn fere si awọn ẹlẹgbẹ rẹ yoku, on si ma awọn ẹgbẹ rẹ [illegible]. O tun fi kun pe, iṣe si awọn kan na ni o da rudurudu silẹ ni ile iṣẹ 'Amele' nigbati awọn enia ati awọn ero inu moto Amele bẹrẹ si sa asala fun emi wọn, ti ọpọlọpọ si nfo igbanu ayika Ilesha "Grammar School".

Ọlọpa na sọpe awọn ọlọpa rogbodiyan ni o tete dekun iṣẹlẹ na ti ko jẹki o rangbaranwọ.

Ki adajọ to sun ẹjọ na di ọjọ kẹtala oṣu yi awọn ọlọpa mẹta Martin Eburebi, Whilly Wacha ati Solomon Adeniran na sọ fi ẹsu won, gbogbo ọrọ won ni asi ba ti oga won Iyare mu.

Ile-ẹjọ ko lati gba idaro awọn mejeji (Ṣango ati Iyanda nigbati ẹjọ mẹta tun ku fun awọn ọmọ ẹgbẹ Dọmọnu mẹtadinlogun, eyiti Ṣango tun wa ninu rẹ ni ọjọ kẹrin oṣu yi kanna.

Ṣaju ọpọlọpọ enia ni o si ti kuro ni ile-ẹjọ nigbati awọn ri ohun ija ti ọlọpa ko lati inu ọkọ ẹgbẹ Akintọla silẹ. Awọn ohun ija na ni aṣaran, kumọ, okuta, adoyẹ ogun ati aake ti awọn ọlọpa gba lọwọ Ṣango.

Okunrin kan sa pamo sinu Apo

Gẹgẹ [illegible] ni ile ifiwe tuntun kan ni Owerri nighati awọn ọlọpa le ọkunrin kan ti awọn fura si pe o fe jale nile to farapamo si inu apo idoho ketulọjọ yi.

Nwọn ni ti ma le si ibudo wọn fun iwadi kikun.

Nwọn ni ọkunrin na wọ ile ifiwe tuntun si Owerri lo lati ba awọn enia ibẹ dapuru, ko pẹ lẹhin ti o ba [illegible] ni olohun iṣẹ ṣe awada na ran, ni o ba pọnta bi ẹgan.

ẸGBẸ ỌLỌPẸ KO LE PARUN

ỌMỌBA Y. A. Sanni ti iṣe akọwe apolongo ẹgbẹ Ọlọpẹ Kano ni, niwọnba igbati babasalẹ ẹgbẹ NPC Ọlọla Bello ko ti le pa ẹgbẹ na run ninu ọdun 1962, ko le parun mọ laelae.

Ọmọba Sanni fi ọrọ na fesi si ọrọ isọkusọ kan ti Olori ẹgbẹ NPC Igbirra Alhaji Adabẹ sọ bayi pe, "Ẹgbẹ Ọlọpẹ ko le ru fin in mọ ni ilẹ Igbirra" nitoripe awọn ọdalẹ ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ kan wọ ẹgbẹ NPC.

O ni iwa ti awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ hu, ko jọ awọn loju rara, nitoripe ọga enia ni nwọn iṣẹ. Ọmọba Sanni sọ bayi pe, ẹgbẹ NPC ni yio ku akurun ni agbegbe Igbira laipe ọjọ.

Ẹka ẹgbẹ Ọdọ Ọmọ Ogun Awolọwọ Kano kansara si Oloye Awolọwọ fun ilekonran ibọro, suru ati ọmumọra rẹ ninu ẹgba ẹwọn.

INIRA BA AWON ENIA

Ẹka ẹgbẹ Ọdọ Ọmọ Ogun Awolọwọ Kano kii laiya laipẹ yi, pe ki o fọkan balẹ, nkan mbọ wa dara laipẹ ọjọ.

Published by the Eastern Post Limited, Elephant House 214 Broad Street Lagos and printed for them by the African Press Ltd, P. O. Box 78, Ibadan, Editor: E. O. OLOFIN, c/o 98, Shitta Street, Ibadan